# Afinimọna Kan

Jeffersonville, Indiana, USA
Ọjọ Kẹrinla, Oṣu Kẹwa, Ọdun 1962

1 Ki Oluwa bukun ọ, Arakunrin Neville. Inu mi dun jọjọ lati tun pada si inu ijọ ni aṣalẹ yii. Ohùn mi ha diẹ. Iwaasu owurọ yii gun diẹ, dajudaju inu mi si dun pe ibi yii ni mo ti wa iwaasu na. Emi fun-ra-mi gbadun rẹ, bi mo ti n mu un wa, mo si ni ireti pe ẹyin naa gbadun gbigbọ ọ pẹlu.

2 Ẹ ma gbagbe bayi, ẹ maa ranti eyi ni gbogbo igba, pe awọn nnkan wọnyii, ni wọn n mu iranṣẹ Kristi dagba. Ẹ rii, igbagbọ ni akọkọ, lẹyin naa, àṣẹ. Wayi, ẹ ranti pe, Ẹmi Mimọ ko lee de ile Ọlọrun ládé titi ti awọn nnkan wọnyii ba fi bẹrẹ si i ṣiṣẹ nipa Ẹmi Ọlọrun naa, ẹ rii. Ohun-yo-o-wu ti o le e ṣe, ẹ rii. Awọn ohun wọnyii ni wọn n mu Ara Kristi dagba, ẹ rii, awọn nnkan wọnyẹn. Wayi, iwọ maṣe gbagbe iyẹn, eyi nihin ni akọkọ, o jẹ igbagbọ rẹ; àṣẹ, ìmọ̀, ati bẹẹ bẹẹ lọ, ni a ni lati fi kun un, titi ti a o fi sọ iduro Kristi ni ẹkunrẹrẹ di ifi-ara-han-fun-aye-ri, nigba naa ni Ẹmi Mimọ yoo wa si ori rẹ ti yoo fi edidi di ọ gẹgẹ bi ara kan. Awọn nnkan wọnyii ni lati wa.

Nitori naa, Jesu wipe, "Nipa èso wọn ni a o fi mọ wọn." Ẹ rii, èso! Iwọ ko lee so èso lai jẹ wipe awọn nnkan wọnyii wa ni inu rẹ lati fi so èso. Nigba naa, nigba ti gbogbo nnkan wọnyii ba gba ipo awọn ifẹ-aye ati aiwa-bi-Ọlọrun ati bẹẹ bẹẹ lọ, nigba naa ni a lé gbogbo aigbagbọ jade, nigba naa ni gbogbo awọn nnkan aye rekọja lọ, ko wa si ohun ti yooku mọ bikoṣe ẹda titun ninu Kristi.

Ati lẹyin naa Efesu 4:30 wipe, "Iwọ maṣe mu Ẹmi Ọlọrun Mimọ binu, eyi ti a fi ṣe edidi yin titi di ọjọ irapada." A ṣe edidi rẹ si inu ijọba Ọlọrun! Wayi, maṣe gbagbe iyẹn. Pa iyẹn mọ si ọkan rẹ bayi, yoo gba awọn nnkan wọnyii ni akoko. Lẹyin naa ifi-edidi-di-ni naa ni Ẹmi Mimọ, eyi ti i ṣe ade ti o n fi edidi di wa si inu ara naa. O dara bẹẹ.

3 A ni ẹbẹ adura kan bayi fun Arabinrin Little, ti Chicago, ọkọ rẹ ni ijamba moto, o si ti wa ni oju iku, iyẹn Arabinrin Little. Ati Edith Wright, arabinrin wa kekere nihin, ti a ti mọ fun igba pipẹ, oun pẹlu wa ni ipo ti ko dara rara rara ni ile rẹ, ni aṣalẹ yii, wọn si fẹ kede eyi fun ijọ, ki gbogbo wa le e gbadura papọ lori ẹbẹ adura yii. Wayi bayi, ẹ jẹ ki gbigbo wa tẹ ori wa ba fun igba diẹ.

4 Baba wa ọrun, ti o ṣe iyebiye, awa n ko ara wa jọ ni ayika (nipa igbagbọ) itẹ Ọlọrun naa, awa si n beere fun aanu lati oke ọrun wa fun awọn ẹbẹ adura wọnyii. Arakunrin little, o ni ijamba moto, o si ti wa ni oju iku. Iwọ Ọlọrun, ran an lọwọ. Njẹ ki Ẹmi Mimọ wa ni ẹgbẹ ibusun rẹ, ki o si mu un pada tọ wa wa, Oluwa. Ati Edith Wright kekere ni isalẹ lọhun, mo gbadura, Ọlọrun, pe ki Ẹmi Mimọ ki o wa ni ẹgbẹ ibusun rẹ ni aṣalẹ yii, ki o si da ilera rẹ pada fun un lẹẹkan sii. Ẹ gba bẹẹ fun wa, Baba. Iwọ ti ṣe ileri awọn nnkan wọnyii, awa si gba awọn ileri wọnyii gbọ. Ati bi awa ba ṣe n ro ni owurọ yii, wipe ọna jinjin ko jẹ nnkan si Ọ. Iwọ jẹ Ẹni ti o wa ni ipa aye kan, gẹgẹ bi iwọ ṣe ri ni ipa aye miiran, nitori pe, Iwọ wa ni ibi gbogbo, O si ni gbogbo agbara, bẹẹ ni O mọ opin lati ibẹrẹ. Awa si gbadura, baba, pe kii ẹ fun wa ni awọn ẹbẹ adura wọnyii nipasẹ orukọ Jesu Kristi. Amin.

5 Inu mi dun jọjọ lati wa nihin lẹẹkan si i lati …Emi si mọ wipe ooru mu. Awọn ipade mẹta ti wọn tẹle ara wọn ni wọnyii, emi si mọ wipe awọn miiran ninu yin si ni bi i ọgọrun marun ibusọ lati fi wa ọkọ̀ lati akoko yii si owurọ Ati lati ọla lọ, emi pẹlu ni igba meje ibusọ lati fi wa ọkọ lẹyin yẹn. Nitori naa, emi gbagbọ wipe o ti jẹ akoko nla fun gbogbo yin. O si ti jẹ asiko nla fun mi lati bẹ yin wo. Ohun kan ṣoṣo pere ni a n bere fun, ọpọlọpọ awọn eniyan ni ati ni ki wọn ki o pada sile nitori wipe ko si aaye ti o to, a ko lee fún awọn eniyan pọ̀jù mọ aaye ti o wa ni aarin ijọ, awon onișẹ-panọpanọ ko ni gba fun wa lati ṣe iyẹn. Nitori naa, awa n gbiyanju lati gba ile-ijọsin ti o tobi ju eyi lọ, ki o lee jẹ wipe nigba ti a ba wa ninu ile, awa yoo lee ni aaye ti o pọ daradara fun awọn eniyan.

6 Ati bayi, nigba-ku-gba, a ki i yin kaabọ nihin si inu Agọ-ijọsin yii, ni ibi ti a ko ni ẹkọ-kẹkọ kan bikoṣe Kristi, a ko ni ofin kan bikoṣe ifẹ, a ko ni iwe kan bikoṣe Bibeli. Ati bayi…. Oluṣọ-agutan wa nihin ni Arakunrin Orman Neville. A si ni awọn ọmọ-ijọ nihin, awọn ọpọlọpọ eniyan ti wọn n ko ara wọn jọ gẹgẹ bi Agọ-Ijọsin ti o gba gbogbo olujọsin lati inu gbogbo ijọ Ọlọrun ti o wa laaye ni wọn, nibi ti eniyan ti lee wa lati jọsin fun Ọlọrun ni ibamu pẹlu ohun ti ẹri-ọkan rẹ ba sọ fun un. Ni gbogbo igba ni inu wa maa n dun fun yin lati jọsin pẹlu wa. Nitori naa, ẹ maa bọ nigba-ku-gba ti ẹ ba lee wa, tayọtayọ ni awa yoo fi gba yin ni gbogbo igba.

Ati bayi, ni igba ti o tun kan ti emi yoo wa pẹlu yin, gẹgẹ bi oye mi ti mo, yoo jẹ nigba ti a ba ti pari kikọ ile-ijọsin yii. Emi si fẹ, lẹyin awọn ẹkọ lori awọn igba ijọ, a fẹ lọ, nigba naa si inu ẹkọ nipa awọn edidi meje ti wọn kẹyin, ani awọn edidi meje ti wọn kẹyin ninu Iwe Ifihan, a ni lati kọ wọn.

7 Ati ọpọlọpọ igba ni awọn alaisan ati awọn ti a n pọn loju n wa, ati ni akoko awọn ipade wọnyii, ni ibi ti a ti n nilo awọn iran, ti a si n wa fun awọn akanṣe ifi-ọrọ-wa-ni-lẹnu wo. Bi mo ba lọ si inu iyẹn, nigba naa emi ko ni mọ iyatọ laarin wọn, yoo si le fun mi lati sọrọ lẹyin iyẹn. Gbogbo eniyan ni wọn si mọ pe ninu awọn ipade ipolongo imularada, pe Ọgbẹni Baxter, tabi ẹlomiiran ni ọpọ igba ni wọn maa n waasu, emi yoo gbadura fun

awọn alaisan ni nitori wipe o maa n nira pupọ diẹ ni. Emi si n gbadura fun awọn eniyan kan ni igba diẹ sẹyin, nigba naa ni mo ba ọmọkunrin kekere kan pade ti awọn dọkita… nnkan kan wa ni ẹyin rẹ, a bii ni ọna kan bẹẹ ni. Nigba ti mo n jade, mo rii ti a joko nibẹ ninu ohun kan ti a rọ, ọmọ yii ko nilo ki o tẹsiwaju lati jẹ arọ bẹẹ, ara rẹ yoo da. O daju, bi o ti ṣe ri niyẹn, ẹ rii, iyẹn ni wipe, emi mọ iyẹn. Ẹ rii, mo ni idaniloju naa. Nitori naa awa fẹ ni igbagbọ wa, a si fẹ gbagbọ ninu Ọlọrun.

8 Ikọọkan ninu yin, ọpọlọpọ yin jẹ alejo si mi, gbogbo eyin oniwaasu ati bẹẹ bẹẹ lọ. Bi n ko ba ṣe aṣiṣe, Arakunrin Crase niyi. Ṣe bẹẹ ni? Arakunrin Crase mo jẹ ọ ni aforiji nitori emi ko wa fun isin iyasimimọ naa. Boya emi yoo wa fun ipade opin ọsẹ kan, iyẹn yoo dara bẹyẹn, ṣe bẹẹ ni? Loke lọhun ni Bloomington. Njẹ ohun gbogbo n dara pẹlu rẹ? O dara. Awon diẹ ninu awọn arakunrin wọnyii jẹ oniwaasu, mo ro bẹẹ. Njẹ oniwaasu ni iwọ bi? Bẹẹ ni, ki Oluwa ki o bukun ọ. Awọn oniwaasu melo ni wọn wa ninu ile yii? Ẹ jẹ ki a ri ọwọ yin. O daa, iyẹn dara bẹẹ. Inu wa dun lati ni i yin nihin, inu wa dun jọjọ. Njẹ ki Oluwa ki o bukun yin titi lae!

9 Wayi, ki a lee pari isin yii, awọn miiran ninu awọn eniyan yii, n lọ si Georgia Tennessee, New York, ati ni ibi gbogbo lati aṣalẹ yii, lati aṣalẹ yii lọ. Wayi, ẹ fi ẹsọ wa ọkọ̀ ni oju ọna. Bi orun ba n kun yin, ti ẹ ko si fẹ ya ile itura, ẹ gbe ọkọ si ẹgbẹ ọna ki ẹ si sun. Ẹ ma wa ọkọ nigba ti orun ba n kun yin. Ohun ti o buru ni eyi jẹ. Ẹ si ranti, kii ṣe nitori tiyin, nitori ti ẹlomiiran yẹn ni, iyẹn ni o ni lati kiyesi, ẹ rii. Iwọ mọ ibi ti iwọ n lọ, iwọ ko mọ ibi ti oun n lọ, nitori naa o ni lati kiyesi ẹni naa. Nitori naa, iwọ rii daju pe orun ko kun ọ rara ni gbogbo igba, o ni lati kiyesi iyẹn. 08:06

10 Wayi, mo fẹ ka Iwe Mimọ kan ti a ri ni Iwe Johanu ni aṣalẹ yii: Wayi, awọn Iwe Mimọ kekere wọnyii ti a n ka, ti a si n tọka si, o yẹ ki wọn fun wa, ni ipilẹ fun ohun ti a n gbiyanju lati sọ. Ati ni gbogbo igba, nigba-ku-gba emi ko lee ranti, pe emi wa si ibi aga iwaasu ri lati sa a sọ ohun kan nitori emi saa fẹ sọ ohun kan. Emi maa n gbiyanju lati ni suuru, mo maa n kiyesara, mo maa n kẹkọ, mo maa n gbadura, titi ti emi fi maa n ni imọlara pe mo ni nnkan kan lati sọ ti yoo jẹ iranlọwọ fun awọn eniyan. Bi emi ko ba lee jẹ iranlọwọ, nigba naa ko wulo fun mi lati wa si ihin, o ri i.

Ohun ti o jẹ ni lati jẹ iranlọwọ! Ati wayi ni aṣalẹ yii, ni tootọ awọn ti wọn pọ ju ninu awọn ero wa ti lọ ni owuro yii, wọn ni lati lọ si ile, ani ọpọlọpọ wọn. Ṣugbọn ni aṣalẹ yii, mo sọ fun un yin pe bi ẹ ko ba lọ, awa yoo gbiyanju lati ba wa sọrọ fun bii iṣẹju marun-di-ni aadọta, nipa ohun kan ti mo ni ireti pe yoo jẹ iranlọwọ fun wa. Emi yoo fi ipinlẹ eyi le ori Iwe Johanu, ori kẹrindinlogun, ẹ si jẹ ki a bẹrẹ ni bi i ẹsẹ keje ti ori kẹrin-din-ni-ogun, ki a si ka a de ẹsẹ karun-din-ni-ogun.

Ṣugbọn ni tootọ ni Emi n sọ fun un yin; anfaani ni yoo jẹ fun un yin bi Emi ba lọ: nitori bi Emi ko ba lọ, Olutunu ki yoo tọ yin wa; ṣugbọn bi mo ba lọ, Emi yoo ran An si i yin.

Nigba ti Oun ba si de, yoo fi oye ye araye niti ẹsẹ, ati ni ti ododo, ati ni ti idajọ.

Ni ti ẹṣẹ, nitori ti wọn ko gba Mi gbọ:

Ni ti ododo, nitori ti Emi n lọ si ọdọ Baba, ẹyin ko si ri mi mọ;

Ni ti idajọ, nitori ti a ṣe idajọ alade aye yii.

Mo ni ohun pupọ lati sọ fun yin pẹlu ṣugbọn ẹ ko le gba wọn nisisiyi.

Ṣugbọn nigba ti Oun, ani Ẹmi Otitọ ni ba de, yoo tọ yin si ọna otitọ gbogbo; nitori ki yoo sọ ti ara Rẹ; ṣugbọn ohunkohun ti o ba gbọ ohun ni yoo maa sọ; yoo si sọ ohun ti n bọ fun yin.

Oun yoo maa yin Mi logo; nitori ti yoo gba ninu ti Emi, yoo si maa sọ ọ fun yin.

Ohun gbogbo ti Baba ni ti Emi ni: Nitori eyi, ni mo ṣe wipe, Oun yoo gba ninu ti Emi yoo si sọ fun un yin.

11 Wayi ni ẹsẹ 13, o wipe, "Ṣugbọn nigba ti oun, ani Ẹmi otitọ ni ba de, oun yoo tọ yin si ọna otitọ gbogbo; nigba ti Ẹmi otitọ naa ba de, oun yoo tọ yin si inu gbogbo otitọ." Kin ni otitọ? ọrọ Ọlọrun ni, "Nitori ti ko ni sọ ti ara Rẹ; ṣugbọn ohun ti O ba gbọ, ni Oun yoo sọ. Ohun ti O ba gbọ, ni Oun yoo sọ "Ni ọrọ miiran, Oun ti Ẹni naa ti yoo fi ohun naa han, o rii. Ni ori kerin Iwe Heberu, Bibeli sọ iyẹn." Ọrọ Ọlọrun ye, o si ni agbara ju ida oloju meji lọ, olumọran ero ati ete ọkan ni o jẹ." O rii, "Ohun ti O ba gbọ ni Oun yoo sọ, Oun yoo si fi ohun ti o n bọ lẹyin ọla han ọ," o rii, kin ni yoo ṣe ohun naa? Ẹmi Mimọ naa yoo wa ni orukọ Jesu Oluwa.

12 Emi yoo si fẹ lo awọn iṣẹju diẹ ti o wa ni iwaju wa bayi lati pe akiyesi rẹ wa si ori ọrọ. "Afinimọna," "Afinimọna kan." Njẹ o mọ, mo ti ni awọn iriri diẹ ninu aginju.

Afinimọna kan jẹ, ẹnikan ti o le e fi ọna han ọ. Iwọ nilo lati ni afinimọna kan nigba ti iwọ ko ba mọ ibi ti iwọ n lọ. Nitori pe mo ti sọdẹ ni ọpọlọpọ ibi ni gbogbo agbaye, mo ti ni anfaani lati pade awọn afinimọna.

Afinimọna kan ni emi funra-ara-mi si jẹ ni Kolorado, nitori mo mọ inu ìgbẹ́ ti o wa nibẹ nipa dida awọn ẹran, ati bẹẹ bẹẹ lọ, emi lee fi eniyan kan mọ ọna ni Kolorado.

13 Wayi, afinimọna ni lati mọ ọna. O ni lati mọ ibi ti o n lọ ati ohun ti o n ṣe, yoo si mọ bi yoo ṣe bojuto ọ ni oju ọna naa, o ni lati rii daju wipe iwọ ko sọnu. Afinimọna jẹ aṣayan ẹda kan. Ijọba; ipinlẹ ni o maa n yan ọkunrin kan bi o ba jẹ afinimọna.

Ati bayi, bi iwọ ba ni lati rin irinajo lọ si inu aginju kan, boya ibi ti ko mọ ọ lara lati maa lọ tẹlẹ ni, kii ṣe ohun ti o dara rara fun ọ lati lọ si inu igbo naa lai ni afinimọna kan lọwọ. Bi o ko ba ni tan ara wa jẹ, awọn ibi kan wa ti iwọ ko gbọdọ daba ati lọ rara lai si afinimọna kan pẹlu rẹ, fun apẹẹrẹ ni Canada. Afinimọna ni lati bu ọwọ lu iwe aṣẹ ti iwọ yoo fun aṣọ-oko-ọba naa. O ni lati fi ọwọ si iwe naa funra-ara-rẹ, ojuṣe rẹ si ni lati bojuto ọ. Bi ohun buburu kan ba ṣẹlẹ si, oun ni yoo dahun fun ọ. O ni lati bojuto irin rẹ nibẹ, O si ni lati ri si i wipe iwọ ko sọnu. O ni lati ri i daju wipe oun ko ran ọ lọ si ibi kan ti iwọ yoo lọ ti iwọ ko si ni mọ ọna lati pada. Bi iwọ ko ba si mọ ọna mọ, o ni lati mọ inu igbo naa daradara ti o ti jẹ wipe oun yoo lee wa ọ jade nigba-ku-gba. O ni lati mọ gbogbo awọn nnkan wọnyii lai jẹ bẹẹ oun ko lee jẹ afinimọna, a ko ni lee fun ni iwe-aṣẹ lati jẹ afinimọna.

Fun iru awọn irinajo bi eyi ni igba miiran, iwọ ni lati ṣe adehun pẹlu afinimọna, iwọ yoo kọkọ pe e, ki o si ṣe eto silẹ, ki o sọ fun un wipe pese aaye silẹ lati ba ọ lọ si inu igbo naa. Ati bi iwọ ko ba…. Ni igba miiran ẹwẹ, iṣẹ le e kun ọwọ rẹ ti ko fi ni lee ba ọ lọ, iwọ si nilati sun irin ajo naa si iwaju fun igba diẹ, iyẹn nipa ti afinimọna ti ile-aye yii. Ṣugbọn iwọ ko ni lati ṣe iyẹn pẹlu afinimọna Ọlọrun, ni gbogbo igba ni Oun maa nwa ni imura silẹ. O wa ni imura silẹ ni gbogbo igba ni.

14 Wayi, bi iwọ ko ba ṣe awọn imura silẹ wọnyii, ti iwọ si n gbera lati rin irinajọ lọ si inu aginju, ni ibi ti iwọ ko i ti i de ri, iwọ lee sọnu, ki o si ṣegbe. Anfaani bintin bayi ni iwọ ni lati jade pada laaye kuro ninu aginju naa, iyẹn bi aginju naa ko ba di pupọ, iwọ yoo ni anfaani diẹ lati jade laaye pada funra-ara-rẹ lati inu aginju naa. Sugbon bi o ba jẹ aginju ti o buru gan an, eyi ti o jiina pupọ si igboro, iwọ ko ni anfaani kankan lati pada laaye kuro ninu aginju naa, ko tilẹ si ọna kan fun ọ lati ṣe e nitori wipe iwọ yoo ri ara rẹ, ti iwọ yoo maa rin irin iku, o si pari pẹlu rẹ niyẹn, o si ti tan pẹlu rẹ niyẹn. Wayii, iwọ yoo si ṣegbe bi iwọ ko ba ni afinimọna ti o mọ inu aginju naa daradara ti o si mọ bi a ṣe n pada laaye kuro ninu igbo naa.

15 Ọpọlọpọ, yin ni ẹ ti mọ nipa ohun ti a tẹ jade lati inu iwe-iroyin naa yi, ti ẹyin ka nipa rẹ ni ọdun ti o kọja ni ilu Tucson, ni Arizona, nipa awọn ọmọkunrin Sikaotu naa. A si ti kọ wọn bi eniyan ṣe n la ninu aginju, wọn jẹ awọn ọmọ-sikaotu. Wọn kii sii ṣe awọn ọjẹwẹwẹọmọ-sikaotu, wọn jẹ awọn akọṣẹmọṣẹ ọmọ-sikaotu. Wọn si rin irinajo lọ si ori-oke nla, ojo yinyin si de, oju-ọjọ yi pada. Wọn wa ri i wipe awọn sọnu, gbogbo wọn si ṣegbe, o jẹ nitori wipe … iyipada de ba bi nnkan ṣe maa n ri ni ọpọlọpọ igba miiran, wọn ko si mọ bi awọn yoo ṣe jade laaye, o rii. Mo si ti gbagbe iye awọn ọmọ-sikaotu naa ti wọn ṣegbe ni ori oke nla naa, bi o tilẹ jẹ wipe wọn ni awọn ọkọ-oju ofuurufu kekeke, awọn ẹgbẹ Ologun, awọn Ẹ̀ṣọ́ orilẹ-ede, awọn eniyan ti wọn fi-inu-findọ fi ara wọn silẹ fun iranlọwọ ati awọn ohun gbogbo bẹẹ. Ṣugbọn awọn ọmọ naa sọnu, ko si ẹnikan ti o mọ ibi ti wọn wa. Wọn ko si lee boju to ara wọn. Gbogbo wọn ni wọn ṣegbe ninu yinyin naa nitori wipe wọn ko mọ bayo ila-oorun, ariwa, iwọ-oorun tabi gusu, oke ni tabi isalẹ ni awọn n lọ, tabi bi ọrọ na ṣe ri, ohun gbogbo jọ ara wọn ni oju wọn ni.

16 Wayi, afinimọna yoo mọ ibi ti oun wa laibikita bi oju-ọjọ ṣe ri. A ti ró o ni agbara lati ṣe bẹẹ. O mọ ohun ti oun n ṣe, ohun gbogbo ninu iju ni o mọ daadaa. O mọ bi ohun gbogbo ṣe ri, nitori naa, o lee wa ninu okunkun ki o si ni imọlara ohun kan.

Fun apẹẹrẹ, ọkan ninu awọn ọgbọn atijọ ti awọn afinimọna ni niyi. Njẹ o mọ, bi iwọ ba lee ri irawọ, ẹnikẹni lee sọ fun ọ, ibi ti iwọ kọ ori si, iyẹn bi iwọ ba wo awọn irawọ oju-ọrun, Iwọ yoo si fẹ wo irawọ oju-ọrun lootọ kan ṣoṣo naa. Irawọ oju-ọrun tootọ kan ṣoṣo ni o wa, eyi si ni irawọ ariwa naa, o rii, ẹyọkan ṣoṣo ni, ojukan ni o maa n duro si. Eyi duro fun Kristi, ọkan ni ana, loni ati titi lai. Awọn irawọ miiran lee ṣako lọ, ṣugbọn Oun maa n duro si ojukan ni: Awọn ijọ lee fa ọ kuro ni oju ọna si ihin, tabi ki awọn kan fa ọ kuro ni oju-ọna si ọ̀hún, ṣugbọn eyi ki i ṣe Oun, ọkan naa ni Oun maa n jẹ.

17 Wayi, bi iwọ ko ba lee ri irawọ ariwa, bi ikuuku ba bo oju ọjọ, nigba naa bi iwọ ko ba ṣe akiyesi, iyẹn bi o ba jẹ ọsan ti iwọ ko si mọ ọna mọ, iwọ ṣe akiyesi awọn igi; Ni gbogbo igba, nipa ti igi, ipa ti o wu olú maa n jẹ ipa ariwa igi nitori wipe, ipa guusu igi maa n gba agbara oorun ju ipa ti ariwa igi lọ. Ṣugbọn ki a wa sọ wipe ilẹ ti n ṣu ti iwọ ko si lee ri ipa igi ti o wu olú. Bi iwọ ba di oju rẹ, ki iwọ má si gbiyanju lati ronu rara, di oju rẹ ki o si wo ẹgbẹ igi ti o n yọ̀, gba igi naa mọra titi ti awọn ìka ọwọ rẹ mejeeji yoo fi kan ra wọn, nigba naa bẹrẹ sii yi igi naa ka diẹdiẹ. Nigba ti o ba de ibi ti epo ara igi naa ti nipọn, ja ọwọ rẹ kuro lara igi naa, ipa ariwa igi naa (ipa ti o n gba atẹgun) ni o de yẹn, nigba naa ni iwọ yoo mọ ibi ti iwọ da oju kọ, boya ariwa ni tabi guusu. Ati ni ọna yii, oo, ọpọlọpọ ọgbọn afinimọna ni o wa, ṣugbọn yoo gba awọn afinimọna lati lee mọ bi a ṣe n ṣe awọn nnkan wọnyẹn. Eniyan kan lasan yoo de ibẹ, yoo si sọ wipe, “Oun ko ri ohun ti o yatọ kankan”, ẹ rii. O rii, a ni

lati kọ ọ nipa iṣẹ afinimọna.

18 Awọn ọmọkunrin wọnyii, ko si iyemeji wọn jẹ awọn ọmọ-sikaotu ti wọn dara, o, ṣee ṣe ki wọn lee fi okun ta koko, o ṣeeṣe ki wọn lee fi okuta ṣana, ati bẹẹ bẹẹ lọ. Ṣugbọn lati mọ ọna lati jade ninu ijù, ohun ti a n sọ niyẹn! Wọn ko mọ ọna lati jade, nitori naa gbogbo wọn ni wọn ṣegbe nitori wọn ko mu afinimọna lọwọ.

Baba alaironu-jinlẹ kan, ni bii ọdun meji sẹyin, ni Kolarado, ooo, o n lọ si ori awọn oke-nla, o ni ọmọkunrin kekere kan ọmọ ọdun mẹfa tabi meje pẹlu rẹ. O fẹ mu ọmọ naa jade fun si sọdẹ-agbunrin rẹ akọkọ. Nitori naa, wọn wa gun ori oke-nla lọ si tente rẹ, ọmọkunrin kekere naa wa sọ fun baba rẹ pe, “O ma n rẹ mi in.”

19 Baba rẹ da lohun wipe, “Jẹ ki n gbe ọ pọn, a ko i ti rin ori oke yii daradara to, awọn agbunrin naa wa ni ori oke naa.” Bẹẹ ni ọkunrin naa n gun oke naa lọ siwaju ati siwaju ati siwaju sii titi ti o … Ọkunrin naa ko mọ, ara igboro ni. Oun ko mọ ohunkohun nipa bi a ṣe n ṣe ọdẹ tabi ibi ti a ti n ṣe ọdẹ. Ẹnikẹni ti o mọ ohunkohun nipa aginju yoo mọ pe awọn agbunrin ki i wa ni tente ori oke, wọn ki i lọ si ori oke. Awọn ewurẹ ni wọn maa n duro nibẹ, kii ṣe awọn agbunrin. Awọn agbunrin maa n wa ni ẹsẹ oke nibi ti wọn ti lee ri ounjẹ jẹ. Wọn ni lati wa ni ibi ti ounjẹ wa, fun wọn lati jẹ. Ṣugbọn ọkunrin yii ro wipe, “Bi mo ba lee gun awọn apata yii de tente ori wọn, nibẹ emi yoo lee ri akọ agbunrin ti o tobi nibẹ.” Oun ti ri aworan agbunrin kan ti o duro ni ori apata, o si wa ro wipe nibẹ ni oun yoo ti ri agbunrin. Iwọ maṣe kọ i bi ara si awọn ohun ti a nkọ sinu awọn iwe-iroyin atigba-degba naa, akiika ooo, akiika, iwọ yoo ni awọn ala kala ni! Ohun kan ṣoṣo ni o ni lati ṣe, o jẹ wipe ki o mu afinimọna kan pẹlu rẹ ki o ma baa sọnu.

20 Ati nipa ti baba ti a n sọrọ rẹ yii, lojiji ojo kan bẹrẹ sii rọ loke nibẹ, awọn ojo ti a ko reti naa. Ọkunrin yi i ṣe ọdẹ pẹ pupọ ju, titi ti ilẹ fi ṣu ti ko si fi mọ ọna lati pada sile mọ. Awọn atẹgun naa si bẹrẹ si i fẹ ni ori oke nla naa, oun si n gbiyanju lati sare sọkalẹ ati pe…

Iwọ ni lati mọ bi a ṣe n la, bi o ba ba ara rẹ ni iru ipo yii. Ohun kan ṣoṣo ni pe ki o mọ ọna ati la! Emi ti ni lati gun awọn igi ki n si maa fi àyà wọ wa silẹ lati ori awọn igi naa, ti emi yoo tun gun awọn igi de oke, ti n o tun yọ́ wa si isalẹ, ti emi yoo maa gun igi de oke ti n o maa sọkalẹ, bẹẹ, lati pa iye mi mọ. Mo ti n lati mu yinyin nigba ti o jẹ ẹsẹ bata mẹrin ni ẹgbẹ kọọkan, ti emi yoo fọ kukute kan ti n o si gbe e kalẹ. Ti ebi yoo maa pa mi to bẹẹ ti n ko fi ni lee dide duro! Emi yoo fọ awọn kukute ti wọn ti pẹ nilẹ to bẹẹ, ti emi yoo si sọ ina si aarin wọn titi ti wọn yoo fi gbona ti wọn yoo si yọ yinyin naa danu. Ati ni bii aago kan owurọ, bii aago meji owurọ, ti emi yoo fa awọn kukute na sẹyin ki emi yoo si fi ẹgbẹ lelẹ lori ilẹ ti o mooru naa, lati lee wa laaye. O si ni lati mọ bi a ṣe n ṣe awọn nnkan wọnyii.

21 Ọkunrin yii ko mọ ohun ti o n ṣe, ko ni ẹnikan pẹlu rẹ lati dari rẹ. O si di ọmọ rẹ mọ ookan aya rẹ titi ti ọmọ naa fi tutu mọ ni aya ti ọmọ naa si ku. Alaironu ẹda! Ibaṣepe o mu afinimọna kan lọwọ pẹlu rẹ ni, oun iba ti mu un wa si isalẹ oke naa laibikita iru akoko ti o jẹ, ẹ rii. Ṣugbọn o duro titi ti ilẹ fi ṣu, nigba naa ni ko riran mọ lati sọkalẹ wa si isalẹ oke naa.

Eyi gẹlẹ ni wahala ti o wa pẹlu awọn Kristẹni ni oni. Wọn n duro titi ti okunkun yoo fi sọkalẹ si ori wọn, nigba naa iwọ yoo wa ri i wipe iwọ ko ni afinimọna kan pẹlu rẹ. Afinimọna naa!

22 Njẹ iwọ ti I ri ọkunrin kan ti o sọnu ri? Njẹ ẹnikẹni ti I ni iriri mimu ọkunrin kan ti o sọnu wale? Eyi jẹ ohun ti o ba ni ninu jẹ julọ ti eniyan ti I ri ri, nigba ti ẹnikan ba sọnu yoo di ẹhanna ni. Ko ni I mọ ohun ti o n ṣe mọ. A mu ọkunrin kan ninu igbo nibẹ, ọmọkunrin kan, o si ti sọnu aginju, o ro wipe oun jẹ ọmọ darandaran daradara ni, ṣugbọn o ba ara rẹ ni agbegbe kan ti ko mọ, o si sọnu, o yi oju rẹ pada sẹyin. Nigba ti wọn si wa a ri lẹyin ọjọ mẹta, o n sare bi I ẹhanna ni, ti o n pariwo ni ohun rara. O ti jẹ gbogbo ete rẹ tan, o sọ ibọn rẹ nu, ko si mọ ohun ti oun yoo ṣe mọ. Ati nigba ti ẹgbọn rẹ funra-rẹ ... nigba ti wọn mu u, ti wọn si de e. Nigba ti ẹgbọn rẹ gan an de ọdọ rẹ, o ba a ja bi ẹranko ni, o gbiyanju lati ge e jẹ ni, ko tilẹ mọ ibi ti o wa mọ. Eeṣe? O ti sọnu ni. Ati nigba ti eniyan kan ba sọnu, o maa n wa ni ipo iporuru ọkan, oun ko si ni i mọ wipe oun wa ni ipo naa, nitori pe, sisọnu naa maa n mu ki o ni arun iba, nigba naa ko ni mọ ibi ti oun wa mọ abi bi oun ṣe n wuwa.

23 Bakan naa ni o ri pẹlu ọkunrin ti o ti sọnu kuro ni ọdọ Ọlọrun! Oun yoo ṣe ohun kan ti o jẹ wipe ni oju lasan ko ni i ṣe. Oun yoo ṣe ohun kan ti eniyan kan ko lee ro wipe eniyan lee ṣe. Ọkunrin kan ti o sọnu kuro lọdọ Ọlọrun, ijọ kan ti o sọnu kuro ni ọdọ Ọlọrun, ijọ kan ti o ti fi Ọlọrun silẹ, ti o ti fi awọn ilana Bibeli Ọlọrun silẹ, ijọ naa nigba miiran yoo ṣe awọn nnkan ti iwọ ko reti lati ri ninu ijọ Ọlọrun alaye. Wọn yoo ko owo wọn jọ nipa ayo bunko, nipa tita ayò, nipa tẹ́tẹ́, ati ohunkohun ti wọn lee ṣe. Wọn yoo gba ohunkohun laaye, fun ẹkọ, wọn yoo ṣe atilẹyin fun awọn ti wọn n ko owo pupọ wa sinu ijọ ati bẹẹ bẹẹ lọ, wọn yoo si gba wọn laaye lati ṣe ohunkohun ti o kuna! Otitọ ni. Wọn yoo yan awọn ti wọn ti ṣe igbeyawo ni ẹẹmẹrin tabi ẹẹmarun gẹgẹ bii diakoni ninu ijọ, wọn yoo jẹ ki wọn ṣe ohunkohun ti o ba wu wọn, ki ijọ lee gbọ awọn bukata wọn. Bukata kan ṣoṣo ni o ni lati gbọ, iyẹn jẹ ojuṣe rẹ fun Ọlọrun. Dide duro ki o sọ otitọ! Awọn ti wọn sọnu wa ni ipo iporuru ọkan, ọkunrin ti ori rẹ daru ni.

24 Afinimọna ni oye, bi a ti n lọ ati ohun ti a ni lati ṣe. Ọlọrun ma n ran afinimọna si awọn eniyan Rẹ. Ọlọrun ko kuna rii. O ran afinimọna, ẹ rii. O ni lati gba afinimọna naa, ẹ rii. O ni lati gba a gbọ. O ni lati lọ ni ọna ti Oun sọ. Bi o ba de aginju, ti afinimọna sọ wipe, "O yẹ ki a lọ ni ọna yi, "ti iwọ si ro wipe o yẹ ki a lọ ni ọna miiran, iwọ yoo sọnu. Nigba naa bi Ọlọrun ba fun wa ni afinimọna lati fi ọna han wa, a ni lati tẹle afinimọna naa. Ko si ohunkohun ti a le maa ro, boya o mu ọgbọn lọwọ tabi ko mu ọgbọn lọwọ, ẹtọ wa kọ ni lati sọ ohun ti o yatọ, afinimọna nikan ni o lee ṣe iyẹn.

25 Ọlọrun ni Majẹmu Laelae ran awọn wolii. Wọn jẹ awọn afinimọna, nitori Ọrọ Oluwa tọ awọn wolii Rẹ wa. Wọn jẹ awọn afinimọna. Wọn dari awọn eniyan bi a ti ṣe gbọ ni aṣalẹ ana nipa Isaiah ati Ussiah. Wọn jẹ adari, wọn dari awọn eniyan, wọn si fi wọn mọ ọna. Bayi, Ọlọrun maa u ran awọn afinimọna Rẹ, Oun ko n ṣe alai ni afinimọna ninu gbogbo awọn iran. Ọlọrun maa n ni ẹni ti o duro fun un ni aye yi, ati ni gbogbo iran.

Bayi, nigba miiran "wọn a maa kuro lọna" gẹgẹ bi a ti ma n sọ ọ. Nigba ti Jesu wa nihin lorilẹ-ede aye, njẹ ẹ ko ranti pe Jesu sọ fun awọn Farisi pe "Afọju afinimọna niyin" Afọju afinimọna ẹyin ti ẹ fọju si awọn ohun ti Ẹmi, ẹ rii. Bayi, o yẹ ki wọn jẹ afinimọna, afinimọna fun awọn eniyan, ki wọn ma jẹ afinimọna si igbala. Ṣugbọn Jesu wipe, "Ẹ fọju!" O si wipe,"Ẹ fi wọn silẹ, nitori bi afọju ba n dari afọju, njẹ gbogbo wọn kọ ni yoo wọ inu koto papọ?" Afọju afinimọna! Oo a ti dibajẹ aye nipa iyẹn, idari pẹlu ifọju ni. Oun ko fẹ ki a gbẹkẹle imọ ara wa. Ọlọrun, ko fẹ ki a gbẹkẹle imọ ara tabi ero ọkan wa, tabi awọn ero ọkan awọn eniyan.

26 Ọlọrun n ran afinimọna, Ọlọrun si fẹ ki a ranti pe ẹni ti Oun yan lati finimọna ni. A si gbọdọ ranti Rẹ. Nihin o sọ bayi, "Emi ko ni fi yin silẹ, ṣugbọn Emi yoo gbadura si Baba, Oun yoo si ran Olutunu miiran" Ani Olutunu yii, nigba ti o ba de Oun yoo dari yin si inu gbogbo otitọ. Ati pe Ọrọ Ọlọrun ni otitọ, Ọrọ naa si ni Kristi, "Emi ni ọna, otitọ ati iye." Oun ni Ọrọ naa, Ọrọ naa, "Ni atete kọ ṣe ni Ọrọ wa, Ọrọ naa si wa pẹlu Ọlọrun, Ọlọrun si ni Ọrọ naa... Ọrọ naa si di ara O si n gbe laarin wa". Nigba naa bi awa ba tẹle afinimọna otitọ, Ẹmi Mimọ, Oun ni o yẹ ki o sọ fun wa ohun ti Oun ti rii, ati ohun ti Oun ti gbọ, Oun yoo si fi awọn ohun ti o n bọ lẹyin ọla han wa. Amin. Nibẹ lo wa, Oun yoo fi awọn ohun ti o n bọ han wa.

Nigba ti awọn ijọ loni ba kọ iyẹn silẹ, bawo ni a ṣe lee lọ si ọrun? Nigba ti a ran Ẹmi Mimọ si wa gẹgẹ bi afinimọna, a wa mu awọn Kadina, awọn Bisọbu, awọn alabojuto tabi ẹnikan bẹẹ yẹn lati jẹ afinimọna fun wa, nigba ti a ti fun wa ni Ẹmi Mimọ lati fi wa mọna.

27 Ẹmi Mimọ si maa n sọ nipa Ọrọ naa. "Mo ni ọpọlọpọ ohun lati sọ fun yin, ẹyin ko lee loye rẹ bayi, ṣugbọn nigba ti O ba de, Oun yoo dari rẹ sii." Eyi ni idi fun wiwa awọn edidi naa. Ni ipari awọn edidi meje, ijinlẹ Ọlọrun yoo pari; lati mọ ẹni ti Ọlọrun jẹ. Oun ti o jẹ. Bi Oun ṣe n gbe, iwa-ẹda Rẹ, ẹda Rẹ, ẹ rii. Eyi n mu wa wa si pipe ọmọkunrin ati ọmọbinrin Ọlọrun, ijọ kan ti a fọ ninu ẹjẹ Kristi, ti a ko rapada pẹlu owo, ti a san owo rẹ nipa ẹjẹ Jesu Kristi.

28 Bayi, bi o ṣe ri niyẹn, afinimọna kan, Oun si jẹ afinimọna ti Ọlọrun pese. Bayi, a n lọ ninu aginju, a si wa ni oju ọna wa lọ si ibi kan, a ko si lee tẹ siwaju lai si afinimọna yii. Ki a ma ri, ki ẹnikẹni fi ẹlomiiran rọpo afinimọna yii! Bi o ba ṣe bẹẹ, yoo mu o kuro ni oju ọna naa. Afinimọna yi mọ ọna! Oun mọ gbogbo ọna kọọkan. Oun mọ gbogbo ero ọkan rẹ. Oun mọ gbogbo awọn eniyan ti a wa nihin. Oun mọ ẹni ti o jẹ ati ohun ti o ti ṣe, ati gbogbo nnkan nipa rẹ. Oun ni afinimọna fun Ọlọrun, ani Ẹmi Mimọ, yoo si fi awọn ye ọ, yoo si sọ awọn nnkan ti o ti gbọ. O lee tun ọrọ rẹ sọ pada ki o si sọ ohun ti o ti sọ. Amin. Yoo sọ ohun ti o jẹ, ohun ti o ni, ibi ti o n lọ. Afinimọna kan, afinimọna otitọ, yoo si tọ ọ si gbogbo otitọ Ọrọ Rẹ. Ọrọ Rẹ si ni Otitọ.

29 Bayi, Ẹmi Mimọ ko lee ṣe "amin" si awọn ero eniyan kan, yoo ṣe "amin" si Ọrọ Ọlọrun nikan, nitori pe bẹẹ ni o ri. Ẹmi Mimọ ko ni dari rẹ si ọna miiran. Bayi, ohun ti o ṣe ajeji niyi, pe gbogbo wa, gbogbo awọn ijọ ẹlẹkọ-adamọ nlanla ati awọn bẹẹ, n jẹwọ pe Ẹmi Mimọ ni o n dari awọn, iyatọ ti o si wa laarin wọn dabi i ti ọsan ati oru.

30 Ṣugbọn nigbati Paulu, Farisi kekere ti o gba Ẹmi Mimọ, nigbati Anania ṣe iribọmi fun, o si lọ si Arabia lati kẹkọ fun ọdun mẹta, o pada de, ko si gba imọran lọwọ ijọ nipa ohunkohun fun ọdun mẹrinla, nigba ti o si de ti o ri Peteru, olori ijọ ni Jerusalẹmu, ero wọn jẹ ọkan naa ninu ẹkọ wọn. Eeṣe? Ẹmi Mimọ kan naa ni! Nibi ti Peteru ti ṣe iribọmi ni Orukọ Jesu Kristi, Paulu ṣe nnkan kan naa lai si ẹni ti o sọ fun. Nibi ti Peteru ti kọ nipa agbara Ẹmi Mimọ ati isọdimimọ, ati bẹẹ bẹẹ lọ; Paulu ṣe nnkan kan naa, lai beere lọwọ ijọ, nitori o jẹ afinimọna kan naa. Eeṣe ti ti awa fi gba ọna ọtọ looni nigbati awọn eniyan n ṣe loodi si awọn otitọ yii? Peteru kọni ni nipa ọna ti a fi le fi ijọ si ilana ti o tọ, Paulu ni iru ẹkọ bẹẹ, nitori wọn ni afinimọna kan naa.

31 Afinimọna ko ni mu ẹnikan lọ siyin, ati ẹlomiiran lọ sọhun, Ki o si ran ẹnikan lọ si ila oorun ati ẹlọmiiran lọ si iwọ oorun. Yoo mu yin papọ. Ati pe bi a ba lee jẹ ki Ẹmi Mimọ mu wa papọ, awa yoo jẹ ọkan. Bi a ko ba jẹ ki eṣu mu wa lọ si ọna ti o kuna, awa yoo jẹ ọ̀kan ninu ọkàn, ọ̀kan ninu èrò, ọ̀kan ni isọkan wa, nipa ẹmi kan, Ẹmi Mimọ, afinimọna Ọlọrun ti yoo tọ wa sinu gbogbo otitọ. Otitọ ni eyi. Ṣugbọn o ni lati tẹle afinimọna rẹ. Bẹẹ ni, saa.

32 Wo Nikodemu, o nilo afinimọna, bi o tilẹ jẹ wipe o jẹ ọkunrin ti o jafafa. O jẹ olukọni, o jẹ ẹni ọgọrin ọdun. O jẹ ọmọ ẹgbẹ ẹ farisi, tabi igbimọ awọn Sahẹndri, ati ti Igbimọ Ẹgbe awọn Oniwaasu. O jẹ ọkan lara awọn ọkunrin to lọla julọ, olukọni ni Israẹli, ọjọgbọn ninu rẹ. Mo ro wipe o jẹ olori olukọni! Bẹẹ ni, o mọ awọn ofin, ṣugbọn ti o ba de ori ti atunbi o nilo afinimọna. Ebi rẹ n pa a. O mọ wipe oun kan ti o yaatọ yẹ ki o wa. Ọna ti o gba lati ba Kristi sọrọ nipa rẹ fi eyi han. O fi imọlara awọn ara iyooku wọn han, ṣugbọn ko si ọkan ninu awọn ti o ni igboya ti oun ni, ko si ọkan ninu wọn ti o lee dide ki o ṣe ohun ti oun ṣe.

Se ẹ mọ, awọn eniyan n bu ẹnu àtẹ́ lu Nikodemu wipe o wa ni oru. O de ibẹ. O gunlẹ nibẹ. Mo mọ wipe awọn kan ko ni lọ boya laarọ tabi laalẹ. Ṣugbọn o de bẹ, o si nilo afinimọna, o si sọ wipe, “Olukọni, awa [lati ẹgbẹ igbimọ Ṣahẹndrin], a mọ wipe O jẹ olukọni lati ọdọ Oluwa wa. ”Bawo ni o ṣe mọ? Jesu jẹ Ẹni ti a jẹrigbe. Ẹ rii, o fẹ mọ ohun ti atunbi jẹ, o si lọ si ọdọ Ẹni ti o tọ nitori Oluwa fi idi rẹ mulẹ wipe afinimọna Oun niyẹn, iyẹn Jesu. Wo ohun ti o sọ, “Olukọni, awa mọ wipe O jẹ olukọni ti o ti ọdọ Ọlọrun wa, nitori pe ko si ẹni ti o lee ṣe ohun ti Iwọ n ṣe yii, ayafi bi Ọlọrun ba wa pẹlu rẹ.”

33 O jẹ ohun ti a fi idi rẹ mulẹ nibẹ, wipe Ọlọrun alaaye wa ninu Rẹ. Ohun ti O jẹri nipa rẹ ni “kii ṣe Emi ni o n ṣe awọn isẹ naa; Baba Mi ti n gbe inu Mi ni. Lootọ ni mo wi fun yin, Ọmọ ko lee ṣe ohun kan ninu ara Rẹ; ṣugbọn ohun ti O ba ri ti Baba n ṣe, ni Ọmọ naa n ṣe pẹlu. Baba n sisẹ, Emi naa n ṣe iṣẹ pẹlu; Ni ọrọ miiran, Ọlọrun n fi i han An ohun ti yoo ṣe, O si n lọ lati ṣe bẹẹ gẹlẹ. Oun ko ṣe ohunkohun ayaafi bi Ọlọrun ba fi I han lati ṣe e. Amin. Otitọ pọnbele nipa rẹ niyẹn. Bi a ba le e kuro ni oju ọna ti a si duro titi ti Ẹmi Ọlọrun yoo fi dari wa lati ṣe! Bi o ṣe ri niyẹn. Ki a wa sọnu patapata si inu Kristi ti ko ni lati ti ọ kaakiri bi O ṣe ma n ṣe si mi, ṣugbọn ni mimi ori Rẹ akọkọ, iwọ ti ṣetan, ko si si ohun ti yoo di ọ lọna, nitori o ti mọ wipe ifẹ Ọlọrun ni.

34 O nilo afinimọna kan. Afinimọna ti a ti fi idi rẹ mulẹ ni. A lee dari rẹ nipa afinimọna yii, nitori o mọ wipe afinimọna ti a mi si lati ọdọ Ọlọrun ni. O mọ wipe awọn aṣa ti o ti ri, boya lati ọwọ awọn Parisi, Sadusi ati awọn orisirisi bẹẹ, o ti sin awọn ẹkọ adamọ ni gbogbo igba ko si ri ohun kan ti o ṣẹlẹ. Ṣugbọn nihin ni ọkunrin kan wa si oju iṣe, ti O sọ pe Oun ni Mesaya ti a ṣe ileri rẹ ninu Bibeli. O si yi pada o si ṣe iṣẹ Ọlọrun naa. Jesu wipe, “bi Emi ko ba ṣe awọn iṣe Baba Mi, nigba naa ẹ maṣe gba Mi gbọ. Ṣugbọn bi ẹyin ko ba gba Mi gbọ, ẹ gba isẹ naa ti mo ṣe gbọ, nitori wọn jẹri gbe Mi.”

35 Nigba naa ko ya wa lẹnu wipe Nikodemu le sọ wipe, “Oluwa, a mọ wipe olukọni lati ọdọ Ọlọrun wa ni Iwọ jẹ, nitori ko si ẹnikẹni ti o lee ṣe ohun ti Iwọ n ṣe yii ayafi bi Ọlọrun ba wa pẹlu rẹ. ”Ẹ rii, o nilo afinimọna, bi o tilẹ jẹ olori nnkan naa, o jẹ olori ninu ijọ rẹ. O ni iyì, ati awọn ipo patakipataki, ati pe o jẹ ọkunrin nla; ko si iyemeji, awọn eniyan ilu rẹ bọwọ fun un. Ṣugbọn nigba ti o di ki a tun un bi, o nilo afinimọna! Bẹẹ naa ni awa pẹlu. A nilo afinimọna kan.

36 Kornẹliu, o jẹ ọkunrin nla kan, ọkunrin ọlọla kan ni. O kọ awọn ile ijọsin. O bọwọ wọ fun awọn Juu nitori o mọ pe ẹsin wọn jẹ otitọ, o si n ṣe itọrẹ aanu, o si n gba adura ni ojoojumọ, ṣugbọn nigba ti Ẹmi Mimọ de (A ti fi nnkan kan kun ijọ) O nilo afinimọna. Ọlọrun ran Ẹmi Mimọ sii. O ran an si i nipasẹ Peteru, “Ṣugbọn nigba ti Peteru n sọ awọn ọrọ wọnyii, Ẹmi Mimọ si ba a le e.” {ohun ti a fi n gba ohun silẹ sofo}

Ọlọrun lo afinimọna nipa Peteru. O lo o, nitori a dari Kọrneliu si ọna ti o tọ́. Ati nigba ti o n sọrọ lọwọ Ẹmi Mimọ ba le awọn Ẹya Alaikọla naa. Nigba naa o wipe, “Njẹ ọkunrin kan lee da ni lẹkun pe ki a ma ṣe ṣe iribọmi fun awọn wọnyii?” Ẹ rii, afinimọna ni o n sọrọ, kii ṣe Peteru. Nitori awọn Ju… tabi, awọn Ẹya Alaikọla. “awọn alaimọ, awọn ti wọn dọti” loju u Peteru, a ti pe ko tilẹ fẹ lọ. Ṣugbọn afinimọna sọ wipe, “Emi n ran ọ lọ.”

Iwọ yoo ṣe awọn nnkan ti o ro wipe iwọ ko lee ṣe, nigba ti afinimọna ba gba akoso patapata, nigba ti o ba jẹ ki O dari rẹ. Haa, bi o ti lẹwa to lati jẹ ki Ẹmi Mimọ dari ẹni. Oun ni afinimọna. Bẹẹ ni.

O sọrọ lati ẹnu Peteru, o si sọ fun un, ohun ti o gbọdọ ṣe. Nigba naa, nigba ti wọn gba Ẹmi Mimọ, o sọ wipe, “Ẹni kan ha le ṣòfin omi, pe ki a ma baptisi awọn wọnyii ti wọn gba Ẹmi Mimọ bi awa pẹlu ṣe gba A ni ibẹẹrẹ.” Wọn si tẹ wọn bọ omi ni Orukọ Jesu. Bayi, tani o dari rẹ lati ṣe iyẹn? Afinimọna ti o wa ninu rẹ ni. Njẹ, Jesu ko sọ fun wọn pe “Ẹ ma ṣe ronu ohun ti ẹyin yoo sọ, nitori kii ṣe iwọ ni o n sọrọ. Baba ti o n gbe ninu ẹ, Oun ni O n sọrọ?” Amin.

37 Iwẹfa ti o n bọ lati Jerusalẹmu mu. Ọlọrun si ni afinimọna kan ni Orilẹ ede aye ni akoko naa, ani Ẹmi Mimọ, Oun si ni ọkunrin kan nibẹ ti a kun pẹlu afinimọna naa. Oun ki i tilẹ i ṣe oniwaasu, O jẹ ọkan lara awọn diakoni. O si wa nibẹ ti o n mu awọn alaisan lara da, o si n lee awọn ẹmi eṣu jade, o si n mu ki isoji ki o ṣẹlẹ nibẹ, ayọ nla si wa ni ilu naa. O ni ọpọlọpọ ọgọrun eniyan ti wọn pejọ si ọdọ rẹ, afinimọna naa si wipe, “Eyi ti to gẹẹ, jẹ ki a pada lọ si ọna ihin.” Ko si ba afinimọna rẹ jiyan.

Laelae iwọ maṣe tako ọrọ afinimọna rẹ. Tẹle e. Bi o ko ba ṣe bẹẹ, iwọ yoo sọnu. Si ranti pe, nigba ti o ba fi silẹ, o wa ni iwọ nikan, nitori naa awa fẹ sunmọ afinimọna wa daadaa.

38 Wayi ni oju ọna naa, Oun wipe “Fi awọn ẹgbẹ yi silẹ bayi, Filippi, ki o si lọ si ọna aginju nibi ti ko si ẹnikẹni. Ṣugbọn Emi n ran ọ lọ sibẹ, ẹnikan yoo si wa nibẹ nigba ti Emi ba mu ọ de ibẹ.” Nihin ni Iwẹfa ti ko ni ẹnikẹni pẹlu rẹ wa, o jẹ eniyan nla kan si aya ọba ni Etiopia. Bayi, oun si n bọ wa, o si n ka iwe Isaiah. Afinimọna naa si wipe, “sunmọ kẹkẹ ogun naa.”

Oun si wipe, “Njẹ oun ti iwọ n ka ye ọ bii?

Oun si wipe bawo ni yoo ṣe ye mi nigba ti ko si ọkunrin kan lati ṣe afinimọna mi?“ Akiika! Ṣugbọn Filippi ni afinimọna naa. Amin. O si wa bẹrẹ lati inu iwe Mimọ kan naa, O si wa waasu Kristi fun un. Amin. Afinimọna! Ko sọ ẹkọ adamọ kan fun un, o sọ fun nipa afinimọna, Kristi! O si ṣe iribọmi fun nibẹ ninu omi kan. O daju, bi o ṣe ri niyẹn. Ooo, mo ni ifẹ iyẹn.

39 Nigbati Israẹli fi Egipiti silẹ lọ si ilẹ-ileri ni Eksodu 13:21, Ọlọrun mọ wipe wọn ko i tii rin irinajo gba ọna ibẹ ri. O jẹ ibusọ ogoji peere, ṣugbọn wọn nilo nnkan lati ba wọn lọ, wọn sọnu ni oju ọna wọn. Nitori naa Ọlọrun ran afinimọna kan si wọn. Eksodu 13:21 ohun kan bi i eyi, “Emi ran angẹli Mi kan si iwaju yin, ọwọn ina naa, lati pa yin mọ ni ọna naa,” lati dari wọn si ilẹ-ileri yi. Awọn ọmọ Israẹli si tẹle afinimọna naa, ọwọ ina (ni alẹ) ọwon ikuuku ni ọsan. Nigbati o ba duro, awọn naa yoo si duro. Nigba ti o ba tẹsiwaju awọn naa yoo tẹsiwaju. Nigba ti O si mu wọn sunmọ ilẹ naa, ti wọn ko si yẹ lati wọ inu n rẹ, O dari wọn pada si aginju. Oun ko si ba wọn lọ.

40 Ohun ti o jẹ niyi, ijọ loni. Ko si iyemeji bikoṣe pe ifi-ara-da Ọlọrun fun wa loni, gẹgẹ bi o ti ri ni awọn ọjọ Noa, ijọ iba ti lọ si ile bi o ba ṣe wipe a tọ ọ si ọna, ti a si gbe e kalẹ letoleto. Ṣugbọn O ni lati maa dari wa lọ yika ati yika a kiri ni

Òye ko tilẹ ye Israẹli daadaa to, nigbati wọn n kigbe, nigba ti wọn ri awọn oku jagunjagun Egipiti, awọn ẹsin ti wọn ri sinu omi, kẹkẹ ogun Farao ti o doju bolẹ ninu odo, wọn ti ni iṣẹgun. Mose ti o n kọrin ninu Ẹmi, Mariamu ti o n jo ninu ẹmi, ati awọn ọmọbinrin Israẹli ti wọn n sare lọ soke sodo ni bebe odo naa, wọn kigbe wọn si n jó, awọn ọjọ diẹ loku fun wara ati oyin. Oye ko ye wọn to pe o si ku ogoji ọdun fun wọn lati de ilẹ ileri nitori wọn bẹrẹ si i kun lodi si Ọlọrun ati afinimọna.

41 Awa si ti ri ara wa ni ọna yii kan naa. Mo lọ si Shreveport lẹyin nihin. Ẹmi Mimọ sọkalẹ ni Ọjọ idupẹ, ni aadọta ọdun sẹyin, ni Lovisiana, ni Ọjọ Idupẹ naa. Aha, bi ijọ ti ṣe ti ṣubu lati igba naa wa! Njẹ iwọ loye pe ni ibẹẹrẹ rẹ, ijọ Aguda ti Roomu naa jẹ ijọ ti Pẹntikọsiti? Otitọ niyẹn. Bẹẹ naa ni. O jẹ ijọ ti Ẹmi Mimọ, ṣugbọn awọn ọtọkulu eniyan ti wọn ko bikita nipa Ọrọ Ọlọrun bẹrẹ si i wọle, wọn si yi iwe Mimọ ti Ọlọrun si igbagbọ asan tiwọn, wọn fi awọn igbagbọ adamọ ati bẹẹ bẹẹ lọ kun un. Iwọ wo ohun ti wọn ni loni, ko si Iwe Mimọ kan kan rara ninu eyikeyi wọn mọ. Wọn fi ohun kan rọpo ohun miiran. Wọn fi burẹdi rọpo Ẹmi Mimọ. Wọn fi omi wiwọn le ni lori rọpo iribọmi. Wọn fi “Baba, Ọmọ ati Ẹmi Mimọ rọpo ”Oluwa Jesu Kristi naa.“ Wọn mu awọn nnkan miiran rọpo awọn ohun Mimọ ti Ọlọrun nla wonyii ti a gbe kalẹ fun wa, wọn si nti wa jiina, wọn jinna rere, wọn jinna gidigidi si awọn ẹkọ Bibeli.

42 Pẹntikọsiti si sọkalẹ ni Louissiana ni aadọta ọdun sẹyin, bi o ba si duro fun igba ọdun miiran, ijọ pẹntikọsiti, yoo jinna rere ju bi ijọ Aguda ṣe ri, bi o ba n tẹsiwaju lati maa ṣubu ni ọna ti o fi n gba ṣubu ni awọn aadọta ọdun ti o ti kọja wọnyii, nitori pe wọn n tẹsiwaju lati fi nnkan kun un ni gbogbo igba ni, lai dawọ duro rara. Awọn oniwaasu ti igba atijọ naa ti tan. Iwọ ko gbọ nipa ipade oju popo mọ. Ohun gbogbo ti a ni loni ni awọn ẹgbẹ Hollywood ti a ti fi kun un, awọn obinrin ti wọn n ge irun wọn ti wọn n wọ ṣokoto penpe, ti wọn n kun oju, ati ohun gbogbo bẹe, sibẹ ti wọn ni Kristẹni ni awọn. Ọmọ Rikky, kekere pẹlu gita, ti o n sare lọ soke-sodo ni ibi yii, ati awọn obinrin pẹlu aṣọ ti o fun mọ wọn lara tintin bi i ti ohun ipanu 'wiener' ti a ti bọ awọ ara rẹ ti awọ ara rẹ fẹrẹ wa ni ode tan, ti wọn n gbọn yika ni ori pẹpẹ, ti wọn sare lọ soke sodo ni ori pẹpẹ, ti wọn n jo pẹlu yẹti gbangba ti o soo rọ ni eti wọn pẹlu ọkan ninu ọna igerun obinrin ti ode oni, ti wọn si n sọ wipe Kristẹni ni awọn.

Ohun ti a nilo ni ẹsin atijọ, eyi ti a ran lati ọdọ Ọlọrun, ti o njo awọ ara ẹni ti yoo jo ifẹ-aye kuro ninu ijọ. A nilo lati pada sinu Ẹmi Mimọ ati ina, ki a pada sinu ohun naa ti o n jo ìda kuro, ki a mu pada wa iwaasu ti atijọ naa ki o n mu ki ọrun ki o ga ati ki ọrun-apaadi ki o gbona, ki a waasu rẹ taara lai ni abula. A nilo iru iwaasu bẹẹ. Ṣugbọn bi iwọ ba ṣe iyẹn ni oni, awọn ọmọ ijọ rẹ yoo fi ibo wọn le ọ jade kuro ninu ijọ.

43 Nigba miiran awọn ọmọ ijọ maa n mu ki a si awọn oniwaasu rere miiran lọna. Idi niyi ti emi ko fi ni ijọ aladamọ kankan. Emi ni olu ijọ kan, ọrun ni iyẹn ti wa. Ibi yoowu ti O ba dari mi lọ ni emi yoo lọ. Ohunkohun ti O ba sọ, ni emi yoo sọ. Awa ko fẹ ijọ ẹlẹkọ adamọ kankan. Bi ijọ yii ba daba ati ni ijọ aladamọ kankan nigba naa a jẹ wipe ẹ ti padanu oluṣọ-agutan an yin nigba naa ni yẹn. Emi ko ni duro ni agbegbe ijọ aladamọ, kii ṣe fun iṣẹju marun un pere. Gbogbo ijọ aladamọ maa n pada si ẹsẹ aarọ ni, iwọ jọwọ sọ fun mi ọkan ninu awọn ti o dide pada. Ẹmi Mimọ ni a ran mi lati dari ijọ, kii iṣe awọn ẹgbẹ kan. Ẹmi Mimọ ni o ni gbogbo ọgbọn. Awọn eniyan n di alaṣa patapata ati alibikita.

44 Ọlọrun sọ fun wọn wipe Oun yoo ran afinimọna kan, Oun ni yoo si dari ọna ati awọn igba ti wọn ba tẹle ọwọn-ina naa, ko si wahala fun wọn. O dari wọn de ẹnu ọna ibode ilẹ ileri, ibi ti o si yẹ ki o dari wọn de niyẹn. Nigba naa Joshua, jagunjagun nla na, ranti ọjọ ti o sọ fun wọn pe, "Ẹ ya ara yin si mimọ, ni ọtunla Ọlọrun yoo lana laarin odo Jọdani nihin awa yoo re kọja si odi keji?" Wayi, ẹ kiyesi ohun ti o sọ (Emi nifẹ eleyi) ninu iwe Mimọ, o wipe "Ẹ duro timọtimọ lẹyin apoti-ẹri naa, nitori wipe, ẹyin ko I ti gba ọna yii kọja ri.

45 Kinni apoti-ẹri naa jẹ? Ọrọ Ọlọrun naa ni. Iwọ ma gba ọna ti ijọ aladamọ rẹ bayi, duro taara lẹyin Ọrọ Ọlọrun naa, nitori pe iwọ ko i ti gba ọna yii kọja ri. Arakunrin, bi akoko kan ba wa ti ijọ Kristẹni yẹ ki o yẹ ara rẹ wo, o jẹ lọwọlọwọ bayi. A ti wa wa ni ibi yii bayi nibi ti ipade nla naa ti nlọ lọwọlọwọ bayi ni ilu Roomu, wọn n yanju awọn ohun ti wọn ni lodi si ara wọn bayi, akorijọpọ awọn ijọ agbaye, nigba ti gbogbo awọn ijọ aladamọ wọnyii n ko ara wọn jọ lati gbe aworan ẹranko naa kalẹ, eyi si jẹ ohun ti Bibeli sọ gẹlẹ. Ẹyin si mọ wipe a sọ eleyi ninu awọn iwaasu naa ni owurọ yii. Awa si niyi bayi taara ninu ohun gbogbo ni ibi ilẹkun naa gan an, ti awọn eniyan si n tẹle ẹkọ kẹkọ. Yoo san fun ọ lati duro lẹyin Ọrọ Ọlọrun naa! Ọrọ Ọlọrun yoo dari rẹ rekọja, nitori wipe Ọrọ Ọlọrun naa jẹ Kristi, Ọlọrun si ni Kristi, ati Ọlọrun si ni Ẹmi Mimọ. Joshua wipe, "Wayii, ẹyin ko i ti gba ọna yii kọja ri, ẹyin ko mọ ohunkohun nipa ọna naa."

46 Wahala ti o n ṣẹlẹ ni oni niyẹn. Iwọ ko nilo afinimọna lati ṣe amọna rẹ loju ọna gbooro naa. Ooo, iwọ mọ gbogbo ọna ere aye ati awọn ohun miiran bẹẹ. Gbogbo ọna ẹṣẹ ni o mọ. Ko si ohun kan … Ooo, iwọ ti wa laye fun igba diẹ. Ko wulo ki ẹnikẹni wa maa ba ọ sọrọ nipa iyẹn, gbogbo awọn ọna àbùjá ni iwọ mọ. Bẹẹ ni, gbogbo ẹṣẹ, iwọ ti mọ gbogbo rẹ. Ko si ẹni ti o ni lati sọ fun ẹ wipe ki o da jale; iwọ mọ iyẹn. Ko si ẹni ti o ni lati sọ fun ọ wipe ki o ṣẹ́ èpè; iwọ mọ iyẹn. Ko si ẹni ti o ni lati sọ fun ọ bi o ṣe ni lati ṣe gbogbo awọn ohun buburu wọnyii, nitori wipe gbogbo awọn nnkan wọnyii wa kaakiri aye.

Ṣugbọn ranti, ẹyin eniyan ti o jẹ Kristẹni, ẹyin ti rekọja si odikeji. Ẹyin ti wa ni ilẹ miiran. A ti tun un yin bi. Ẹ ti wa ni ilẹ kan, ilẹ ti ọrun, Ẹ ti wa ni ilẹ-ileri.

47 Ẹ mọ ọna yin yi kaakiri nihin. Ooo, akiika, bẹẹ ni. Ẹ mọ bi ẹ ṣe lee duro lori ọwọ kaadi kan ti o daju. Ẹ mọ daisi nigba ti o ba yi, ẹ mọ ohun ti eyi tumọ si, ati ohun gbogbo bẹẹ. Ṣugbọn nigba ti o ba de ori pe ki a mọ nipa iwa mimọ ati iwa ododo ati agbara Ọlọrun, ati bi Ẹmi Mimọ ṣe n ṣe iṣẹ ati awọn ohun ti o n ṣe, yoo ṣe yin ni anfaani lati duro lẹyin Ọrọ Ọlọrun, afinimọna naa, ẹ rii. Ẹyin ko i ti igba ọna yi kọja ri.

O dara, iwọ wipe, "Emi jẹ ọkunrin kan ti o jafafa diẹ, mo ti gba oye meji lati fasiti." Iba san fun ọ ki o tete gbagbe iyẹn. Bẹẹ ni.

"Emi ti lọ si ile-iwe nipa ẹkọ ẹsin." Yoo san fun ọ ki o gbagbe iyẹn. Yoo ṣe ọ ni anfaani lati lọ si ẹyin afinimọna naa ki o si jẹ ki O dari rẹ. Oun mọ ọna naa. Iwọ ko mọ on. Iwọ ko i ti i gba ọna yii kọja ri. "O daa" iwọ wipe, "awọn ti gba ọna yi kọja ri."

Woo bi wọn ba ti gba a koja. Jesu wipe, "Awọn ti wọn ti gba ọna naa kọja, awọn ami wọnyii yoo tẹle wọn. Ni orukọ Mi, wọn yoo le awọn ẹmi eṣu jade, wọn yoo fi ade titun sọrọ; bi wọn ba gbe ejo lọwọ tabi ti wọn mu ohun oloro kan eyi ko ni pa wọn lara. Bi wọn ba gbe ọwọ wọn le awọn alaisan, ara awọn alaisan yoo da." Awọn ti wọn pọ ju ninu wọn, kọ ọ, wọn ṣẹ ẹ, wọn ni Ọrọ naa ko tilẹ ni imisi. Awọn wọnyii ko tẹle afinimọna naa. Wọn n tẹle ẹkọkẹko agbelẹrọ ẹniyan. Yoo ṣe ọ ni anfaani ki o to si ẹyin Ọrọ Ọlọrun naa, nitori wipe iwọ ko i ti i gba ọna yii kọja ri, iwọ mọ.

48 Ṣugbọn ati tun ọ bi, a si ti bi ọ sinu iwa mimọ. Iwọ ko i ti i gba ọna yii kọja ri. Bi iwọ ba gba ọna yii, iwọ ni lati gba ọna iwa mimọ kọja, nitori wipe ilẹ titun ni. Igbesi aye titun, awọn eniyan titun ni wọn.

Iwọ yoo wa si ile ijọsin iwọ yoo si gbọ ti ẹni kan yoo dide ti yoo si kigbe pe, "Ogo ni fun Ọlọrun! Alleluya! "Eeṣe, iwọ yoo wipe, "Kaasa, ohun oluwa mi, awọn ko ṣe iru ohun bi eleyi ni ijọ mi ri! Emi yoo dide emi yoo si jade! "Yaa sọra o.

Tò si ẹyin Ọrọ Ọlọrun, wayi, jẹ ki afinimọna dari rẹ. "Oun yoo dari rẹ sinu gbogbo otitọ, yoo si fi gbogbo nnkan wọnyii ti Emi ti ba ọ sọrọ nipa rẹ han ọ. Oun yoo si sọ fun ọ awọn ohun ti n bọ lẹyin ola han ọ," iyẹn afinimọna tootọ. Maṣe lọ ba Bisọbu o, iwọ lọ ọ ba ẹlomiiran yatọ si afinimọna naa. Oun ni a ran lati fi ọna han ọ. Oun ni ẹniti yoo ṣe iṣẹ naa. Ọlọrun ti pese afinimọna kan fun ọ. Iwọ gba ọna ti Ọlọrun ti pese naa.

Wahala ti o n ṣẹlẹ loni ni eleyi ni pe awọn eniyan ti wọn n wa sinu ijọ saa n joko fun igba diẹ ni, awọn ohun kan si n ṣẹlẹ ti ko mọ wọn lara.

49 Mo mọ riri obinrin kekere kan lati inu awọn ijọ alasa ati ijọ ti o tutu naa, mo ṣẹṣẹ gbadura fun un tan ni. Ọlọrun yoo mu obinrin kekere naa lara da. Ohun ko loye eleyi, ko tilẹ mọ ohunkohun nipa rẹ. O wọle, oun wipe oun ko mọ. Ṣugbọn emi ko sọ fun un pe, oun n bọ wa ri mi. Onitiju ti o nfa sẹyin diẹ ni, ṣugbọn afinimọna naa n tẹsiwaju o n sọ fun un, "Maa tẹsiwaju." O ti wa yee. Bi o ṣe ri niyẹn. O ri i, o jẹ nitori Ẹmi Mimọ naa ti o n ṣe amọna rẹ si awọn nnkan wọnyii. O rii, Ọlọrun ni ọna ti o ti pese silẹ.

50 Nję iwọ nigba-ku-gba …? Nję iwọ ti n kiyesi awọn pẹpẹyẹ igbẹ ti wọn n lọ, awọn pẹpẹyẹ ti wọn n lọ si gusu? O dara, wayi ranti, a bi pẹpẹyẹ kekere naa ni odikeji nibi adagun odo nibikan. Oun ko mọ ila-oorun, ariwa, iwọ-oorun ati gusu. Ko mọ ibikan bikọṣe ibi adagun odo naa ti o wa ni ibi awọn oke-nla ti Kanada. Oun ko i ti ni fi igba kan kuro ni ibi adagun odo naa ri. Ṣugbọn a bii gẹgẹ bi a dari.

A bi akọ pẹpẹyẹ kekere naa gẹgẹ bi i adari. Ati ohun akọkọ, ni alẹ ọjọ kan yinyin nla kan sọkalẹ ni ori awọn oke naa. Kinni o ṣẹlẹ? Atẹgun tutu naa sọkalẹ wa si isalẹ nibẹ. Mo le e ro o wo wipe akọ pẹpẹyẹ yii bẹrẹ sii gbọn, o wipe, “Mama mi, kinni eleyi tumọ si?” Ẹ rii, oun ko i ti i ni imọlara oju ọjọ ti o tutu bii iyẹn ri. O wa bẹrẹ si kiyesi ni ayika naa ... oun bẹrẹ si kiyesi ni awọn ẹgbẹ adagun odo naa pe emi naa ti bẹrẹ si di, yinyin ti n bọ si ori adagun odo naa. Oun ko mọ, ṣugbọn lojiji...

A bi akọ pẹpẹyẹ yii gẹgẹ bi afinimọna fun awọn pẹpẹyẹ naa. Oun yoo wa bẹ soke taara si aarin adagun odo naa nigba ti otutu naa wa si ara rẹ. Iwọ pe e ni ohunkohun ti iwọ ba fẹ. Awa maa n pe e ni imisi, tabi iwọ pe e ni, ooo, ọgbọ-inu, tabi ohunkohun ti o jẹ. Oun yoo fo kuro ni aarin adagun odo naa, yoo gbe iko rẹ kekere naa soke, yoo si maa lọ, “họnku-họnku-họnku! ”Gbogbo awọn pẹpẹyẹ ti wọn wa ni ori adagun odo naa yoo si wa ba a. Eeṣe? Wọn mọ olori wọn ni ọna ti o fi n gba kigbe họnku họnku naa.

51 “Bi ipe ko ba fọn ohun ti o daju, tani yoo gbáradì fun ogun?” Bẹẹ ni tani yoo pese ara rẹ fun ogun bi ipe ko ba fọn ohun ti o daju.

O dara, bi pẹpẹyẹ kekere naa ba fọn ohun ti o daju, tani yoo pese ara rẹ fun fifo naa? Pẹpẹyẹ kekere naa yoo gbe imu rẹ soke yoo si pari wo, “họnku-họnku, họnku-họnku!” Gbogbo awọn pẹpẹyẹ kekere naa yoo si tọ ọ wa. “Họnku-họnku, họnku-họnku.” Gbogbo wọn si ti de. Ariwo ayọ nla ni wọn yoo si ni, taara lati aarin adagun odo naa, wọn yoo maa yi ara wọn pada siwaju ati siwaju sii. Lẹyin igba ti o ba ṣe oun yoo wa ni imọlara kan ti o n wa si ara rẹ nigba naa o ni lati gbera. Oun yoo wa naa awọn iyẹ rẹ kekere naa silẹ, yoo si fo kuro ninu adagun odo naa, yoo gbera lọ si oju ọrun yoo si yipo ni bii igba mẹrin ati marun un yoo si wa fo taara lọ si Louisiana bi o ṣe lee fo to, gbogbo awọn pẹpẹyẹ ti wọn ku ni wọn yoo si tẹle e. “Họnku-họnku, họnku-họnku,”o ti n lọ niyẹn. Eeṣe? Afinimọna ni o jẹ! Amin! Awọn pẹpẹyẹ mọ afinimọna wọn, ijọ ko mọ ọn. Bẹẹ ni, oun mọ ohun ti o yẹ li oun ṣe.

52 Iwọ wo gbogbo awọn pẹpẹyẹ ti wọn ti dagba naa, taara ni wọn n wa lati Alaska. Wayi, akọ pẹpẹyẹ kan ti o ti gbo wa, oun ni o maa n dari wọn, gbogbo awọn pẹpẹyẹ naa ni lati yẹ akọ pẹpẹyẹ naa wo daadaa. Wọn ni lati mọ ohun ti akọ pẹpẹyẹ naa n sọ. Nję iwọ ka iyẹn ninu “Iwe-Iroyin Look, ”nihin ni bii ọdun mẹrin sẹyin, nigba ti akọ pẹpẹyẹ kan ti o ti gbo ko mọ ohun ti o n ṣe, o si dari awọn ẹgbẹ pẹpẹyẹ naa lọ si ilu Ọba-binrin Oyinbo? Bẹẹ ni. Awọn pẹpẹyẹ yii ko i tii de ilu Oba-binrin Oyinbo ri. Eeṣe? Awọn pẹpẹyẹ kan ko kiyesi adari wọn. Akọ pẹpẹyẹ ti o ti gbo naa ko mọ ibi ti o nlọ. Ati bayi gbogbo wọn ti wa nibẹ wọn ko si lee pada wale mọ.

53 Ohun ti o n ṣẹlẹ pẹlu ọpọlọpọ awọn pẹpẹyẹ wọnyii niyẹn, wọn si n korajọpọ sibẹ. Wọn wipe, iyẹn, “Iwe iroyin Atigbadegba Look, wipe, awọn pẹpẹyẹ wọnyii maa n korajọ papọ wọn si n fo yika gbogbo England, ṣugbọn wọn ko mọ bi wọn yoo ṣe pada sile. Bi o ṣe ri niyẹn pẹlu ọpọlọpọ awọn pẹpẹyẹ wọnyi ti mo mọ nipa wọn. Wọn n ni ikorajọpọ ati awọn ipade ti wọn maa n gun, wọn si n mu awọn onisọji kan lati wa lati waasu fun igba diẹ, ṣugbọn ẹyin ko mọ ibi ti ẹyin n lọ. Kikorajọpọ layika ati layika, nitori pe ẹ ti ni akọ pẹpẹyẹ kan ti yoo dari yin lọ sinu awọn ijọ ẹlẹkọ-adamọ pẹlu awọn eto yafun yafun, ti wọn ko si pada sinu Ọrọ Ọlọrun, ti wọn ko pada sinu, ti wọn ko si pada sinu ibaptisi Ẹmi Mimọ. Lẹyin naa, o wa n ṣe wọn ni kayeefi idi ti iroyin ko fi waye ni awọn ọjọ wa, ẹ rii. Iwọ ni lati ni ohùn ti o daju naa! Ohun naa ni iro ipe ihinrere ti o n mi imi ihinrere jade, iyẹn gbogbo Ọrọ Ọlọrun. Kii ṣe ẹkọ-kẹko, tii ṣe ijọ ẹlẹko-adamọ; ṣugbọn Bibeli ni, Ẹmi Mimọ ni. ”Awọn ami wọnyii yoo maa ba awọn ti wọn gbagbọ lọ,“ ẹ rii. Nibẹ ni wọn n lọ si isalẹ ọna naa.

54 Gbogbo akọ pẹpẹyẹ kan nigba kan, wọn wipe, o ko awọn pẹpẹyẹ lọ sinu iku, nigba ti o n gbiyanju lati mu wọn fò gba inu okunkun kan kọja, oun funra-ara-rẹ ko mọ ibi ti oun n lọ, gbogbo wọn ni wọn si kọlu oke-nla kan nita nibẹ awọn kan ninu wọn si fọ yanga, wọn si ku danu. O daa bẹẹ! Wọn gbudọ mọ iro wọn ti o daju. Pẹpẹyẹ ogbologbo kekere naa, ki a wa sọ wipe o ni ohùn ti o daju ni, ti gbogbo wọn si mọ ọn, wọn i ba ni, ikorajọpọ alayọ ati taara ni wọn ba lọ si iha gusu. Kinni wọn lọ si ibẹ naa fun? Nibi naa ti ko si otutu.

Wayi, bi Ọlọrun ba fun pẹpẹyẹ ni ọgbọn inu ti o tọ lati mọ ati sa fun otutu, bawo ni Oun iba ti mọ to lati fun ijọ Rẹ ni ọgbọn inu naa. Bi pẹpẹyẹ ba lee ṣe iyẹn pẹlu ọgbọn-inu, melo melo ni yoo ri bẹẹ pẹlu Ijọ ti Ẹmi Mimọ? Eyi yẹ ki o dari wa kuro ni awọn aṣa lasanlasan ti atijọ ati awọn ẹkọ-kẹkọ ati awọn ohun bẹẹ, lọ sinu ibaptisimu Ẹmi-Mimọ ti o logo ti o si yanilẹnu, nibi ti awọn iwa rere Ọlọrun, imọ, suuru, iwa-bi-Ọlọrun, ti wa ninu Ẹmi mimọ. Ohun ti afinimọna tootọ yoo dari ẹni si inu rẹ niyẹn, nitori pe oun ko ni ni imi kankan jade bikọṣe ihinrere, ani Ọrọ Ọlọrun nikan. Eyi daju, iwọ nilo afinimọna!

55 Ni akoko awọn amoye naa, wọn ko mọ ohunkohun nipa Ọlọrun. Wọn jẹ awọn osiṣẹ pidanpidan, awọn pidanpidan ni wọn. Wọn wa ni iha ila-oorun agbaye. O mọ, Bibeli sọ wipe, “Awa ti ri irawọ Rẹ ni iha-Ila-Oorun, awa si wa lati fi oribalẹ fun Un.” Wọn wa lati Iwọ-Oorun, wọn wo ila-oorun wọn si ri Irawọ Rẹ ... tabi

wọn n wo iwa-oorun, wọn wa ni ila-Oorun. Awa wa ni Ila-Oorun, ẹ rii. “Awa ti ri irawọ Rẹ ni ila-Oorun. ”Iwọ woo, wọn wa ni ila-oorun. “Nigba ti awa wa ni Ila-Oorun awa ri irawọ naa, awa si ti wa lati fi ori balẹ fun Un.”

56 Mo le e ro o wo wipe awọn eniyan wọnyii ti n gbaradi lati lọ. Mo lee ro pe aya ọkan ninu wọn sọfun un wipe, “Iwọ ti di gbogbo ẹru rẹ, ṣugbọn atọna rẹ da?”

O wipe, “Emi ko nilo atọna ni akoko yii.”

“O daa, bawo ni iwọ yoo ṣe la awọn oke-nla naa kọja?” Ranti, wọn ni lati la Odo Tigris kọja, ki wọn si sọkalẹ, ki wọn si la awọn ilẹ ti wọn fẹju naa kọja ati irinajo naa gba wọn ni ọdun meji lori ibakasiẹ. Ọgbọn wo ni wọn yoo ta sii? O wipe, “Iwọ ko si mu atọna lọwọ rara.”

O wipe, “O ti o.”

“Bawo ni iwọ yoo ṣe lọ?”

“Emi n gba ọna ti Ọlọrun ti pese silẹ lọ. Irawọ ti o wa ni odikeji naa ni yoo dari mi de ọdọ ọba naa. ”Bi o ṣe ri niyẹn.

“Awa ti ri irawọ Rẹ ni Ila-Oorun, a si tẹlee ni gbogbo ọna de ihin ni iwọ-oorun, lati wa fi ori balẹ fun Un. Nibo ni O wa?” Wọn tẹlee ọna ti Ọlọrun ti pese. A de wọn mọ awọn ẹgbẹ ẹlẹkọ-kẹkọ kan nisalẹ lọhun fun igba diẹ. Wọn de Jerusalẹmu, wọn wa bẹrẹ si i lọ ni oju popo, awọn eniyan wọnyii ti wọn mura daradara, ti wọn n wipe, “Oun naa da? Oun naa da? Ẹni ti a bi gẹgẹ bi Ọba awọn Juu?” Oun daa, iyẹn jẹ Olori, eyi ti o wa ni Jerusalẹmu. Dajudaju o yẹ ki ijọ nla naa mọ ohun kan nipa rẹ. “Ọlọrun da?” Oun naa da Ẹni ti a bi gẹgẹ bi Ọba awọn Juu? Awa ti ri irawọ Rẹ ni Ila-oorun, awa si ti wa lati wa fi ori balẹ fun Un. Oun da?“

Eeṣe, wọn lọ ba oluṣọ-aguta lagbaja ati lakasegbe, wọn si lọ si ọdọ olori-alufaa, lagbaja ati lakasegbe, ko si eyikeyi ninu wọn ti o mọ ohunkohun nipa rẹ, “Eeṣe ti a fi bi ọba kan ti i ṣe Ọba awọn Juu, oun da?” Awọn ko mọ.

57 Ṣugbọn awọn ẹgbẹ oluṣọ-agutan kan wa nita nibẹ ni ẹgbẹ oke kan, ti wọn ni akoko ti o dara, bẹẹ ni, nitori wipe wọn ti tọ ọna ti Ọlọrun la silẹ.

Bẹẹ ni wọn duro nibẹ, ati taara o wipe “Emi yoo sọ fun ọ ohun ti o yẹ ki a ṣe, o yẹ ki a ni ipade igbimọ kan.” Nitori naa wọn pe awọn igbimọ Sahẹndiri, wọn ro o wo pe boya wọn mọ ọ ohunkohun nipa rẹ. “O ti o, awa ko mọ ohunkohun nipa rẹ o.”

Bakan naa ni o ri gẹlẹ loni. Wọn ko mọ ohunkohun nipa afinimọna yii. Ẹmi Mimọ ti o n wonisan, ti o n kun ni, ti o n gbanila, ti o n pada bọ yii. Olumọran ero ọkan ni; wọn ko si mọ ohunkohun nipa iyẹn, wọn n pe e ni afọsẹ tabi ohun miiran bẹẹ. Wọn ko mọ ohun ti wọn iba sọ nipa rẹ.

58 Nitori naa, njẹ iwọ ri awọn ọkunrin amoye naa, niwọn igba.… Ranti, nigba ti wọn wọ Jerusalẹmu, wọn ko ri irawọ naa mọ. Ati niwọn igba ti o ba n wa ẹkọkẹkọ ati awọn ọkunrin ti ijọ ẹlẹkọ adamọ lati dari rẹ si ọdọ Ọlọrun, iranlọwọ Ọlọrun yoo fi ọ silẹ. Ṣugbọn nigba ti ọrọ rẹ ṣu wọn ti o si rẹ wọn, ti wọn si fi wọn silẹ, ti wọn fi ẹkọkẹkọ ati ijọ ẹlẹkọ-adamọ ti awọn Juu wọnyẹn silẹ, ti wọn si jade kuro ninu ilu Jerudalẹmu, nigba naa ni irawọ naa fi-ara-han lẹẹkan sii wọn si yọ pẹlu ayọ nla ati eyi ti o taayọ. Lẹẹkan sii wọn ri afinimọna naa! Ooo, bawo ni o ṣe jẹ, iwọ fi awọn ijọ atijọ naa, ti wọn tutu ti wọn si jẹ ti alaṣa silẹ, nigba naa pada sinu ijọ ti o dara ti o si n gbina fun Oluwa, ki o si ri afinimọna naa ti yoo dari, iyatọ nla ni eyi yoo jẹ! Bẹẹ ni, “Awa ti ri irawọ Rẹ ni Ila-Oorun, awa si ti wa lati fi ori balẹ fun Un”.

59 Joshua sọ fun wọn pe, “Wayi ẹ tẹle apoti-ẹri naa, nitori pe ẹyin ko i ti gba ọna yi kọja ri.” Ọlọrun ko ni gba apoti-ẹri naa lati gba ọnakọna ayafi ọna ti o tọ. Gbogbo wọn ni wọn tẹle e, taara lọ Jọdani kọja.

Bakan naa ni o ri ni oni yii, nipa Ẹmi Mimọ tabi bẹẹ kọ, awa ri ifihan-fayeri rẹ, ifihan-fayeri rẹ ti o n jẹri gbe Ọrọ Ọlọrun.

60 Wayi, laipẹ yii, awọn ara kan ni ẹjẹ ati ororo, ko si buburu nipa iyẹn bi wọn ba fẹẹ ṣe e ni ọna yẹn. Loju temi, eyi kii ṣe ijẹrigbe. O jẹ ijẹrigbe ti Iwe Mimọ, ẹ rii niwọn igba ti o ba n jẹri gbe ohun ti Ọlọrun sọ, iyẹn dara bẹẹ. Wọn wipe, “Ẹri niyi pe o ni Ẹmi Mimọ, nitori pe, ororo n da jade ni atẹlẹwọ rẹ. ”Wayi, emi ko le e gba iyẹn gbọ, ẹ rii. Ẹmi ko gbagbọ pe ororo ni ohunkohun i ṣe pẹlu rẹ. Bi eyi ba jẹ fun iwọsan ati igbala, kinni o wa ṣẹlẹ si ẹjẹ Jesu Kristi? Bi ororo naa ba n wonisan, bawo wa ni ti ina Rẹ? Ẹ rii? Ẹ rii?

Mo nifẹ pe ki afinimọna naa ki o wa, eyi ni yoo mu ọ wa sinu otitọ ti Ọrọ Ọlọrun, nigba naa iwọ pẹlu mọ wipe iwọ ti wọle niyẹn, o si ti mura silẹ fun igberasọ. Bi o ṣe ri niyẹn, o ti n gbaradi lati fo lọ. Bẹẹ ni. Otitọ ni, nitori kinni? Afinimọna naa ni ẹni naa ti yoo jẹ ki o jẹ arigbamu.

61 Mo ni Iwe Mimọ kan nihin, mo ti fun yin ni Iwe Mimọ yi i tẹlẹ, ṣugbọn mo fẹ ka eyi. Peteru keji ni, Ori kinni, ẹsẹ kọkanle-logun.

Nitori … asọtẹlẹ ko wa nigba atijọ nipa ifẹ eniyan: ṣugbọn awọn eniyan mimọ Ọlọrun sọrọ bi a ṣe dari wọn nipa Ẹmi Mimọ.

Bawo ni asọtẹlẹ ṣe wa? Ki i ṣe nipa ifẹ awọn eniyan, ẹkọkẹkọ ijọ adamọ; ṣugbọn nipa ifẹ Ọlọrun, nigba ti a mi si awọn eniyan Mimọ nipa Ẹmi Mimọ. Oun ni o ma n jẹ afinimọna Ọlọrun. Eyii jẹ Ẹmi Mimọ ti o wa ninu ọwọ ina naa, eyi ni Ẹmi Mimọ naa, ẹnikẹni mọ wipe Kristi ni. Mose fi Egipti silẹ, o ka ẹgan Kristi si ọrọ̀ ti o pọju, awọn iṣura Egipti lọ, Kristi ni ẹni naa! Bayi nigbati wọn ba duro nibẹ ti wọn wipe, “Bayi, o sọ wipe o wa. Nigbati o ko ti i ju ọmọ aadọta ọdun, O si wipe Iwọ ri Abrahamu?”

Oun wipe, “ki a to bi Abrahamu. Emi ti wa.” Emi ni Ẹni ti o pade Mose ninu ọwọ ina ninu ina ti o n jo ninu iju. Bẹẹ ni, sa. Oun ni Ọlọrun ti o di ẹran ara. Kii ṣe ẹni kẹta; Ẹnikan naa ni ofisi ti o yatọ. Kii ṣe awọn Ọlọrun mẹta, ipọ mẹta ti Ọlọrun kan. Otitọ pọnbele ni.

62 O dara, wayi, Iwe mimọ naa. Ni gbogbo igba, bi Ọlọrun ba pese. O maa n pese ohun ti o dara julọ. Nigba ti Ọlọrun ba pese lati ró ijọ Rẹ lagbara, O maa n Un pese ohun ti o dara julọ. Nigba ti O fun Adamu ati Efa, ninu ọgba Edẹni, ohun ti O fun wọn ni Ọrọ Rẹ. “Nigba ti o ba wa labẹ Ọrọ yii, o wa ni ailewu. Ṣugbọn bi o ba kuro kuro labẹ rẹ, ọjọ ti o ba jẹ ninu rẹ, ọjọ naa ni iwọ yoo ku. ”Ọlọrun ki i yi eto Rẹ pada. Eṣu naa ko ti yii eto rẹ pada bẹẹ. Bi o ṣe wọ aarin Adamu ati Efa, bẹẹ naa ni o ṣe n wọ inu wọn loni. kin ni? Nipa lilo ero wọn lati gbe Orọ Ọlọrun wo. “Wayi, ohun to mu ọgbọn lọwọ ni pe Ọlọrun ko ni ṣe bẹẹ. Ooo, Ọlọrun ti sọ pe,” Ọlọrun ti sọ pe, ni satani wi, “Ṣugbọn ni tootọ Ọlọrun Mimọ ko ni ṣe eleyi.” Dajudaju Oun yoo ṣe bẹẹ nitori O sọ pe Oun yoo ṣe bẹẹ!

63 Nnkan ti awọn eniyan n sọ loni niyẹn. “Ooo, wayi duro naa! O ko gbagbọ bayi, bi mo ba lọ si ile ijọsin ti mo san awọn idamẹwa mi, ti mo si ṣe eleyi, ati tọhun, ṣe Ọlọrun yoo wa jami kulẹ bi? ”Ayafi ti ẹnikan ba di atunbi, oun ko tilẹ lee loye ijọba Ọọrun! Ẹ rii? Ko si awọn awawi! “ Wayi, ọkunrin arugbo ti o talaka, obinrin arugbo ti o jẹ talaka, ọkan ti o dara ni wọn. Ọna kan ti wọn fi le e ri Ọlọrun ni ki a tun wọn bi. O pari. Emi ko fẹ mọ bi wọn ṣe kere to, bi wọn ṣe dagba to, bi wọn ṣe jẹ ọdọ to, ohun ti wọn ṣe, bi wọn ṣe maa n lọ si ile ijọsin to, iye awọn ijọ ẹlẹkọ-adamọ ti wọn mọ, iye ẹkọ adamọ ti wọn lee tun sọ. O ni lati di atunbi laijẹbẹ iwọ ko tilẹ si lori ipilẹ ti ibẹrẹ. Bẹẹ gẹlẹ ni o ṣe jẹ.

64 Ẹ rii, o nilo afinimọna na. Oun yoo tọ ọ si ọna otitọ, otitọ si ni Ọrọ Ọlọrun. Oun yoo tọ ọ si ọna. Ati pe bi o ti maa n ri niyẹn. Ọlọrun ko nilo lati yi ohun kan pada, nitori o jẹ ẹni airi, O si mọ ohun ti o tọ. Oun wa ni ibi gbogbo, Oun si n ri ohun gbogbo, O jẹ, ohun gbogbo. Bi o ṣe rii niyẹn, Ọlọrun jẹ ohun gbogbo, nitori naa ko lee yi pada. Bẹẹ ni.

Oun Ọlọrun ni Olufimulẹ ọna ti o fi n dari eniyan. Ẹmi Mimọ afinimọna naa ni Olufimulẹ ti Ọrọ Ọlọrun kan naa ti O n kọ ni. Bayi, a dari Luku nipa afinimọna lati sọ pe “Ẹ lọ si gbogbo aye, ẹ waasu ihinrere naa fun gbogbo ẹda. Ẹni ti o ba gbagbọ ti a si ṣe iribọmi fun ni a o gbala, ẹni ti ko ba gbagbọ ni a o da lẹbi. Ami wọnyii ni yoo maa tẹle awọn ti wọn gbagbọ; ni orukọ mi ni wọn yoo lee awọn ẹmi eṣu jade, wọn yoo fi ede tuntun sọrọ, wọn yoo gbe ejo oloro lọwọ, wọn yoo mu awọn nnkan oloro, wọn yoo gbe ọwọ lee awọn alaisan, a o si wo wọn san.” Bibeli sọ wipe, “Wọn lọ si gbogbo ibi,” afinimọna n dari wọn, ẹ mọ, “wọn waasu ọrọ naa, pẹlu ami ti o n tẹle wọn.” Ki wa ni eyi? Afinimọna ti o n fi idi naa mulẹ wipe o jẹ Otitọ!

65 Ilana Ọlọrun niyẹn. Bi a ṣe gbe kalẹ niyẹn. Eto Rẹ niyẹn; Oun ko lee yii pada kuro ninu iyẹn, nitori O jẹ Ẹni ailopin. Amin. Oun ko lee yi pada kuro ninu iyẹn; Oun ni Ọlọrun. Emi lee yi pada; nitori mo jẹ eniyan. Iwọ naa lee yi pada; nitori o jẹ ọkunrin tabi obinrin kan. Ṣugbọn Ọlọrun ko lee yii pada. Mo jẹ ẹni ti o ni opin; mo le e ṣe asiṣe ki n si sọ awọn ohun ti o kuna, gbogbo wa lee ṣe eyi. Ṣugbọn Ọlọrun ko lee ṣe bẹẹ, ki o si jẹ Ọlọrun. Ipinnu Rẹ akọkọ jẹ pipe. Bi Ọlọrun ṣe ṣe ni oju iṣe kan, bẹẹ ni ọna ti yoo fi maa n ṣe ni akoko kọọkan. Bi a ba pe E wa si oju iṣe lati gba ẹlẹṣẹ kan la, ti O si gba a la nipa ọna kan. Igba miiran ti ẹlẹṣẹ kan ba wa, O ni lati wuwa ni ọna kan naa, lai jẹ bẹẹ, O kuna ni ọna ti o gba ṣe e ni igba akọkọ. Amin. Mo ni ifẹ Rẹ. Mo mọ wipe o jẹ otitọ.

66 Mo jẹ ọmọ ọdun mẹta-le-laadọta, mo si ti n waasu nihin fun ọdun mẹta-le-lọ-gbọn ati aabọ, emi ko ti i ri ki o kuna. Emi ti ri i ti a dan an wo ni igba meje kaakiri ori ilẹ aye, ninu gbogbo awọn ẹsin ati gbogbo nnkan miiran, ni iwaju bi i idaji miliọnu kan ni akoko kan, ko si fi igba kan kuna rii. Emi ko sọrọ lati inu awọn iwe, mo n sọrọ lati inu iriri mi, nitori mo mọ wipe Ọlọrun maa n duro ti Ọrọ Rẹ, O si maa n bu ọla fun un. Bayi, bi o ba ni ẹkọ adamọ kan, yoo san ki o kiyesi iyẹn. Ṣugbọn Ẹmi Mimọ yoo duro ti Ọrọ Ọlọrun.

Ninu Iwe Johanu Ori Kinni, ati ẹsẹ kinni, O wipe, “Oun ni Ọrọ Ọlọrun. Oun ni afinimọna naa. Ni atetekọṣe ni Ọrọ wa, Ọrọ si wa pẹlu Ọlọrun, Ọlọrun si ni Ọrọ naa, Ọrọ naa si di Eniyan O si n gbe laarin wa.” Akiika!

67 Adari Peteru lati sọ ni Iwe Awọn Aposteli, ori keji ẹsẹ keji-dinlogoji (Acts.2:38). bi a ṣe lee gba Ẹmi Mimọ, o wipe, "Ẹ ronu piwada, olukuluku yin, ki ẹ si ṣe iribọmi ni orukọ Jesu Kristi fun imukuro awọn ẹṣẹ yin ati lẹhin naa afinimọna yoo mu ọ tẹsiwaju lati ibẹ̀ lọ" Bẹẹ ni, ohun ti o yẹ ki o ṣe niyẹn. Lakọkọ ronu piwada awọn ẹṣẹ rẹ, aigbagbọ rẹ, ti o ti fi ṣe aigbagbọ si awọn nnkan wọnyii. Ronupiwada, ki a si ṣe itẹbọmi fun ọ, afinimọna naa yoo mu ọ lati ibi yi lọ. O rii, ojuṣe rẹ niyẹn. Ojuṣe rẹ ni lati ronupiwada. Ojuṣe rẹ ẹ ni lati ṣe iribọmi. Nigba naa o wa jẹ ojuṣe afinimọna lati mu ọ lati ibẹ lọ, yoo dari rẹ lati iwa rere si imọ, si ipamọra, si suuru, si iwa bi Ọlọrun, si ifẹ ara, Ẹmi Mimọ yoo si fi edidi di ọ. O rii. Nigbana o wa di ẹkunrẹrẹ iduro Ọlọrun, ọkunrin Ọlọrun gidi, obinrin Ọlọrun gidi, ti idakọro rẹ duro ninu Kristi. Emi ni ifẹ iyẹn, ẹni ti idakọro rẹ duro ninu Kristi.

68 Bẹẹ ni, adari Marku nipa Ẹmi Mimọ, lati kọ Marku ori kẹrin-din-logun, ni tootọ ni.

Adari Johanu nigbati o kọ Iwe Ifihan. Adari rẹ nipa afinimọna. A si tun dari rẹ nipa afinimọna naa lati sọ pe, "Ẹnikẹni ti o ba mu Ọrọ kan kuro ninu rẹ tabi ti o fi ọrọ kan kun un, oun naa ni a o yọ ọ, ipa rẹ, kuro ninu Iwe Iye."

Bayi, bawo ni o ṣe maa fi ohun miiran rọpo Ọrọ Ọlọrun, ki o si tun sọ wipe a adari rẹ nipasẹ Ẹmi Mimọ? Eleyi ko mu ọgbọn wa, njẹ o mu ọgbọn wa? Rara o ti o. Ko mu ọgbọn wa.

69 O ti maa n jẹ afinimọna mi ni gbogbo aye mi. Oun maa n dari mi si iye. Oun ni o dari mi sii iye, Oun si ni iye aye mi. Lai si I, emi ko ni iye. Lai sii, emi ko fẹ ohun miiran. Oun ni ohun gbogbo fun mi. Ni wakati iṣoro mi, O duro ti mi. Lana O bukun mi, Loni O ti ṣe nnkan kan naa. Kin ni ki n tun reti? Ọkan naa ni titi lae, ẹ yin orukọ Rẹ logo! Bẹẹ ni: O ṣe ilẹri rẹ. Oun yoo si ṣe. Oun ni iye mi, Oun ni atọna mi, ohun gbogbo ninu ohun gbogbo ni O jẹ fun mi. Mo ti gbẹkẹle le E. Mo ti ni awọn iṣoro ti o lagbara. Mo maa n gbẹkẹle nibi kibi ti mo ba n lọ. Mo fẹ ki iwọ naa ṣe bẹẹ. Bi ẹ ba lọ fọ aṣọ, ẹyin obinrin, ẹ gbẹkẹle. Bi ẹ ba n lọ si aarin ilu, ẹ gbẹkẹle.

70 Nigba kan mo de ipo kan ti mo ro wipe mo jẹ ẹni ti o mọ nipa aginju daradara, ṣe ẹ mọ, mo ti ṣe ọdẹ pupọ pupọ. Mo lero wipe, "Mo jẹ ẹni ti o jafafa rekọja, ko si ẹni ti yoo.…O ko lee sọ mi nu. Mama mi jẹ abala kan India, mo si ni ifẹ iyẹn. Ooo, akiika! O ko lee sọ mi nu ninu, aginju, mo mọ ibi ti mo wa."

Bẹẹ ni mo gbera lọ…igbadun lẹhin igbeyawo mi, mo rẹ́ iyawo mi jẹ diẹ, mo sọ fun, "Njẹ o mọ Oyin, yoo jẹ ohun ti o dara fun wa lati ṣe igbeyawo ni ọjọ kẹtalelogun Oṣu Kẹwa. Nitori, ọjọ ti Oluwa sọ fun mi pe ki n ṣe niyi.

Mo si ro o wipe, "Wayi, fun faaji kekere lẹyin igbeyawo! Mo ti fi owo mi paamọ, emi yoo gbe e lọ si Odo Niagara, a si lọ si Adirondack lati ṣe ọdẹ diẹ, "o rii. Nitori naa mo mu oun ati Billy, Billy jẹ ọmọ kekere kan. Nitori naa mo ni lati mu un lọ fun faaji lẹhin igbeyawo, o si jẹ irinajo ọdẹ siṣe pẹlu, ṣe o mọ. Nitori naa mo lero wipe eyi yoo jẹ nnkan ti o dara lati ṣe. Nitori naa mo mu un lọ.

71 Mo kọ iwe si Arakunrin Denton, aṣọgbo naa. Awa si n lọ lori Oke Hurricane. Mo si wipe," Arakunrin Denton, mo n bọ loke, mo fẹ ṣe ọde awọn beari ni akoko ọ̀gbẹlẹ̀ yii"

O si wipe, "O dara, Billy, ma bọ" O sọ wipe, "Oun yoo wa ni ori oke naa ni ọjọ bayi ati bayi. O daa, iyawo mi ati emi de ibẹ ni igba ti o ku ọla ti oun yoo de, ati Billy, bẹẹ naa ni a ba ile pako naa ni titi pa, ile ahere kan si wa ninu igbo naa.

Nibiti Arakunrin Fred Sothman ati emi lọ laipẹ pupọ, a si duro nibẹ. Ẹmi Mimọ, mo si ri ti O duro nibẹ, ina alawọ omi ọsan naa ti o n lọ kaakiri inu igbo naa, ati Fred si duro sibẹ. O sọ ọ wipe, "Wa si apakan, mo fẹ ba ọ sọrọ, Lọla, "wipe "Ṣọra, wọn ti dẹ pakute fun ọ. O wipe, "jẹ ọlọgbọn." ṣe bẹẹ ni, Arakunrin Fred? "Mo si lọ, mo si sọ fun awọn ọgọrun eniyan ni alẹ ọjọ naa, ni ilu Vermont, mo wipe, "Pakute wa ti a ti dẹ silẹ fun mi; n o si rii. Mi o mọ ibi ti o ti n bọ."Ni alẹ ọjọ keji, nibẹ ni o ti wa, nibẹ ni o wa. O wipe, "Eyi ni pakute ti a dẹ silẹ fun ọ. Bẹẹ ni, sa. Ṣugbọn Ẹmi Mimọ dari mi ninu ohun ti mo n ṣe. Ati, akiika, iyẹn saa tọna bẹẹ! Haa, ọpọlọpọ yin mọ ohun ti o jẹ. Emi koni akoko to lati sọ ọ.

72 Ṣugbọn nigba ti mo duro nibẹ yẹn ni akoko yẹn, otutu si bẹẹrẹ si mu, ni ọjọ yẹn Arakunrin Denton n pada bọ ni ọjọ keji, mo wipe, "se o mọ oyin, iba ti dara ti mo ba lee ri akọ agbọnrin mu lọ si i ile." Mo wipe, "Mo ni lati fi awọn owo ẹyọ kan pamọ́, a ṣẹṣẹ ṣe igbeyawo ni. Ati wipe, "A ma ni ẹran fun akoko otutu yii bi mo ba lọ ṣe ọdẹ kekere loni.

O wa sọ pe, "O dara, Billy, tẹsiwaju." O wipe, "Wayi, iwọ ranti pe emi ko i ti de inu igbo yii ri o." O sọ wipe ibusọ marun-le-logun ni ori oke nla ni oun wa yii, iwọ mọ, o sọ wipe, "Emi ko mọ ohun kan nipa eleyi."

O tun sọ pe, nitori naa mo ….

73 Mo wipe, "o daa, wayi, iwọ ranti, o jẹ ọdun meji sẹyin ti mo pa awọn beari mẹta naa. Eyi jẹ lẹyin lọhun ni

ori oke ni odi-keji lọhun.” Mo wipe, “Emi yoo pa akọ agbọnrin ti o tobi kan, a o si pa awọn beari kan,” emi si wa wipe, “awa yoo ni ẹran ti a o jẹ ni akoko otutu.” O daa, iyẹn dabi ẹni pe o dun daradara, o mọ. (A si sa awọn èso berry dudu, a si wa eedu wa fun igba otutu naa, ati lẹyin naa Billy si tan wọn, Meda ati emi si maa n ṣa wọn ni irọlẹ lẹyin ti mo ba kuro ni ibi iṣẹ aṣọgbo mi). Nigba naa mo wipe, “Emi yoo lọ gba ibọn mi, mo n lọ si ihin.” Mo wipe, “ọpọlọpọ agbọnrin ni o wa nihin, emi yoo ri ọkan pa. ”Mo si wipe, “Iwọ mọ, ”mo wipe, “emi yoo lọ pa a. ”Mo si tun wipe, laipẹ pupọ emi yoo pada de“

74 Nitori naa, nigba ti mo gbera kuro, oju ọjọ ko mọlẹ daadaa. Ẹyin ara New Hampshire ati oke lọhun ni New England, ẹ mọ ohun ti o tumọ si nigba ti ikuuku ba bo oju ọjọ tabi ni ibikibi ni ibomiiran ni awọn ori oke na, iwọ ko ni mọ ibi ti o wa mọ. O tan. Iwọ ko ni le e ri ọwọ rẹ ni iwaju rẹ. Nitori naa mo wa bẹrẹ lati la igbo kekere kan ti o n mi kọja, mo wa sọkalẹ, mo si gun oke kekere kan mo wa lọ si oke. Mo wa kiyesi ẹkun kan, ohun ti ẹ n pe e ni apá orilẹ-ede yii niyẹn. Awa ti a wa ni iwọ Oorun maa n pe e ni Kuga. Wọn n pe e ni kiniun loke lọhun. Ẹranko kannaa ni. Ẹranko 'puma' ni, ohun ti o jẹ nitootọ niyẹn. Ẹkun kannaa ni, bi ẹsẹ-bata mẹsan ni gigun rẹ, o wọn iwọn meji-le-laadọjọ tabi igba poun. O re oju ọna naa kọja, mo si yọ kẹlẹ kiakia mu ibọn mi, ṣugbọn emi ko yara to lati ta a ni ibọn.

75 O dara, mo yọ kẹlẹ gun oke kekere kan, ti mo n le ẹkun yii, mo n wo awọn ewe ni ibi ti o gba lọ, o mọ. Emi ko lee gbọ Ọ. O ni ẹsẹ mẹrin. Mo mọ wipe kii ṣe ẹranko ẹlẹsẹ meji, ẹranko ẹlẹsẹ mẹrin ni. Mo si mọ wipe ki i ṣe agbọnrin, nitori agbọnrin maa n bẹ lulẹ ni. Oun n yoo lọ ni, ẹkun ni, o mọ, bẹẹ. Beari maa n yi ẹsẹ ni nigba ti o ba n rin. Nitori naa mo mọ wipe kiniun oke nla ni o nilati jẹ. O si wa ni ẹyin iti igi kan emi ko si rii, bi mo ṣe ri i fẹrẹ bayi, o ti lọ.

Mo si wo ibi ti o ti n da awọn ewe ru, o mọ, ni ori oke nla naa ati bi o ṣe n lọ si isalẹ bayi. Emi ko si kiyesi i bi kurukuru naa ti n sọkalẹ ni gbogbo igba yii, iwọ mọ, bi ikuuku naa ti n sọkalẹ. Mo yọ kẹlẹ lọ si isalẹ, mo la afonifoji nla naa kọja, mo si wa lọ si inu aginju naa, ti mo n tẹle ẹranko yii. Mo ro pe, “Ọwọ mi yoo ba a laipẹ,”Pe emi yoo ri ibi kan, pe emi yoo sare gun ibi giga kan, emi yoo si wo yika a kiri bẹẹ, emi yoo si yọ wo gbogbo ayika naa, ki n wo boya mo lee rii, mo tẹti silẹ, daradara, mo sọkalẹ, mo tun yọ kẹlẹ lẹẹkan sii. Mo lee gbọ ti igbo n daru lọ, ni iwaju iwaju mi bi ẹranko naa ṣe n sa jade. O rii, o n kọlu awọn igi nigba naa nko lee tọ pinpin rẹ mọ. O rii, o wa ja fafa, o mu igi gun, o si bẹrẹ sii fo lati ori igi kan de ekeji. Nigba naa, o wa mọ wipe emi ko le e maa tọ pinpin oun mọ. Ooo, mo ro o wipe, “O ti dara, lọnakọna.”

76 Mo si bẹrẹ sii rin pada lọ ninu afonifoji ti ko ni omi naa, mo si gbọ oorun biari kan, akọ biari ti o ti gbo kan. Mo wa ri wipe, “Emi yoo pa a bayi, haa ọmọkunrin, iyẹn dara! ”Mo tun fi imu finlẹ fun oorun rẹ lẹẹkan sii. Mo tun rin si iwaju, mo n gbiyanju lati kiyesi orisirisi ami ti mo lee ri ati ohun gbogbo bẹẹ. Nko lee ri ohun kan; mo tun pada sẹyin lọ si isalẹ, mo si tun lọ si ẹgbẹ keji ti oke nla naa. Nigba naa ni mo wa bẹrẹ si kiyesii pe, ikuuku ti bẹrẹ sii bo oju ọjọ. Mo ti gbiyanju lati gbọ oorun biari naa lẹẹkan sii, oorun n wa lati ibikan. Mo wipe, “O ti o. Wayi, kinni o ṣẹlẹ, atẹgun naa n fẹ bọ lati ihin yii oorun biari naa si n wa lati isalẹ nihin, mo si ti rekọja ni agbegbe yii, atẹgun naa si n fẹ wa lati iha yii. Nitori naa mo ni lati pada sẹhin si ibiti mo ti kọkọ gbọ oorun rẹ, emi yoo si bẹrẹ lati ibẹ.”

77 Ati mọ oju ọna mi pada, mo wo iwaju ninu afonifoji gbigbẹ naa, mo rii wipe igbo n mi. Nigba ti mo si ri bẹẹ, ohun dudu kan gbera. Mo wa ro o wipe “Ẹran naa niyẹn. ”Mo wa ki ibọn mi ni kiakia, mo si duro jẹẹ. Nigba ti o si mira, mo ri i wipe, o jẹ akọ agbọnrin nla, o jẹ eyi ti o tobi daadaa. Mo wa ro wipe, “Iru eyi ganan ni mo ti n wa.” “Mo yin akọ agbọrin naa nibọn.

Mo roo wipe, “O dara!” Emi ko si kiyesi i o ti n jẹ…. Ni akoko ti mo yanju ẹran mi tan, mo wo… mo nu ọwọ mi, mo nu ọbẹ mi, mo si daa pada. Mo wa roo wipe, “Yin Ọlọrun logo! Oluwa Jesu, O ṣe o. O ti fun mi ni ẹran ti emi yoo jẹ ni akoko otutu. Iyin ni fun Ọlọrun ”Mo si gbe ibọn mi. Mo wa ro wipe, “Emi yoo pada taara si inu afonifoji gbigbẹ naa nihin.” Mo wipe, “ Wo ihin, ọmọkunrin, iji naa ti n bọ. Yoo ṣe mi ni anfaani ki n tete nihin ki n si pada si ọdọ Meda ati awọn iyooku,” Mo wipe, “Mo ni lati kanju.”

78 Mo wa bẹrẹ si i lọ ninu afonofoji gbigbẹ naa, mo tu bọtini kootu mi pupa ti o tobi naa, mo si bẹrẹ sii sare lọ ninu afonifoji gbigbẹ naa bi eleyi yika, ohun akọkọ, o mọ, mo ro o wipe, “Nibo ni mo ti n ya kuro wọ ihin? Mo lọ yika. Mo mọ wipe mo n lọ taara si oke Hurricane. Ṣugbọn mo wa duro, mo n laagun, mo ro o wipe, ”Kinni o n ṣẹlẹ gan an nihin? Mo ti lọ fun ọgbọn iṣẹju tabi iṣẹju marun un din ni aadọta, emi ko si mọ ibi ti mo ya wọ ilu afonifoji gbigbẹ naa mọ.“ Mo wo oke, mo si n wo agbọnrin mi. Mo ri pe mo ti pada si ibi ti mo ti n bọ. Mo roo wipe, ”Kinni mo ṣe?“

79 O dara, mo tun bẹrẹ pada. Mo ro o wipe, “Emi yoo jana ni akoko yii, ati pe emi ko kiyesi ọna ni.” Mo wa kiyesi ohun kekere gbogbo, nibi gbogbo mo n kiyesi wọn. Mo bẹrẹ sii wa ọna, mo n wa ọna, mo n wa ọna. Awọn ikuuku naa si ti bẹrẹ si i bọ, mo mọ wipe atẹgun pẹlu yinyin naa ti bẹrẹ sii bọ, ikuuku ti o lagbara ti wa ni oju ọrun, nigba naa ni mo wa bẹrẹ si i kiyesi i. Mo ro wipe, “Emi yoo tẹsiwaju diẹ si i,” mo n lọ, mo n lọ, mo n lọ, mo n lọ, mo n lọ, mo n lọ, mo n lọ. Mo wa ro o pe, “O daa o, eyi ṣe ajeji, pe o dabi ẹni pe mo ti ri ibi yii

ri.” Mo si wo, bẹẹ ni mo n wo agbọnrin mi ti mo gbe kọ igi, ẹ rii.

Njẹ iwọ mọ iru irin naa ti mo n rin? Awọn ara India maa n pe e ni “irin iku.” Iwọ n rin ni obiripo, yika ati yika a kiri. O dara, mo ro wipe mo jẹ afinimọna ti o dara ju lati sọnu. Ẹ rii, ko si ohun ti o le e fi ọna han mi ninu aginju; mo mọ gbogbo ọna ti inu igbo naa, ẹ rii.

80 Mo rin si oke afonifoji naa diẹ, lakoko yii atẹgun naa ti bẹrẹ si i fẹ. Kaasa, akiika, yinyin ti wa ni ibi gbogbo! Okunkun ti fẹrẹ bo gbogbo ilẹ tan, mo si mọ wipe Meda yoo ku ni oru ọjọ na ninu aginju, ko mọ bi oun yoo ṣe bojuto ara rẹ. Ati Billy, ọmọ bi i ọdun mẹrin tabi mẹta ni, ẹni kekere kan ni. Mo si wa ro o wipe, “Kinni wọn yoo ṣe?” O dara, mo ti rin de ibi ti mo de yii mo si wa de ibi ebe awọn olu kan, mo wa ro o wipe, “Mo ti wa ni ilẹ ti o tẹju pẹrẹsẹ kan, bẹẹ ni emi ko ri nnkan kan mọ, ikuuku ti o lagbara ti bo oju ọjọ.” Mo sa a n yipo rin kiri ni bayi.

Bi ko ba si awọn nnkan miiran ti o rọ mọ ọn, emi iba ti wa ibi kan sun si bi mo ba ni ẹnikan pẹlu mi. Emi i ba fi ara pamọ ti n ba duro titi ti iji naa yoo fi lọ, ni bii ọjọ kan tabi meji ti n ba si jade sita nigba ti o ba ya. Emi iba pọn agbọnrin mi sẹyin, n ba wọle, n ba jẹun, n ba gbagbe ohun gbogbo nipa rẹ. Ṣugbọn iwọ ko lee ṣe iyẹn nigba ti iyawo ati ọmọ rẹ wa ninu aginju nibẹ, ti wọn n ṣegbe lọ, o rii.

81 Nitori naa, mo wa bẹrẹ si i ro o pe, “Kinni ki n ṣe?” Nitori naa, mo tun rin siwaju. Mo si ro wipe, “Wayi, duro o. Nigba ti mo rekọja afonifoji akọkọ, atẹgun n fẹ lu mi ni oju ni. Nitori naa, mo ti ni lati gba ọna yii kọju tẹlẹ. Mo ti ni lati gba ọna yii bayi. ”Mo si ti ṣakolo si inu awọn aginju didi naa, ṣugbọn emi ko mọ ibi ti mo wa mọ. Mo wipe, “Ooo! Ara mi si i bẹrẹ si i gbọn. Mo wa ro wipe, ”Duro ni iṣẹju kan o, Billy, iwọ ko sọnu,“ mo n gbiyanju lati lo ogboju fun ara mi. Iwọ ko le e lo ogboju kankan nipa rẹ, o ti o, o ti o. E rii-ọkan ti inu naa n sọ fun ọ wipe o ti kuna.

Ooo, iwọ n gbiyanju lati sọ wipe, “Ooo, o ti gba mi la, mo kuku n lọ sinu ijọ kan.” Iwọ ma mikan, duro de igba ti akoko iku naa ba de, iwọ yoo mọ wipe iyatọ wa nigba naa. Ẹri-ọkan rẹ n sọ fun ọ. Ohun kan ninu rẹ n sọ fun ọ pe o kuna, o rii. Iwọ mọ wipe bi a ba ku iwọ ko lee pade Ọlọrun Mimọ naa. Gẹgẹ bi a ti ri i ni alẹ ana, awọn angẹli mimọ paapaa ni lati fi iboju bo oju wọn lati lee duro ni iwaju Rẹ. Bawo ni iwọ yoo ṣe duro lai lo ẹjẹ Kristi lati bo oju rẹ?

82 Mo wa ro wipe, “Ooo, emi yoo jana,” Mo tun bẹrẹ pada. Mo wa rii wipe mo bẹrẹ sii gbọ ohun kan. Ara mi bẹrẹ sii gbọn. Mo wa roo wipe, “Wayi, bi mo ba ṣe eyi, ohun gbogbo yoo daru fun mi ni.” Ni ọpọ igba ohun ti ẹni ti o ba sọnu maa nṣe niyẹn, ohun gbogbo yoo bajẹ fun un ninu igbo. Nigba naa ni yoo mu ibọn rẹ, yoo si ta a mọ ara rẹ, tabi ki o ṣubu si inu ogbun kan ki ẹsẹ rẹ si kan, ibẹ ni yoo si sun si, ti yoo si ku si ibẹ. Nitori naa mo wa ro o wipe, “Kinni emi yoo ṣe bayi?”Nitori naa mo wa bẹrẹ sii rin lọ.

Mo si bẹrẹ sii gbọ nnkan kan ti o n sọ wipe, “Emi ni iranlọwọ ni akoko wahala. ”Mo saa fẹ tẹsiwaju mo n rin lọ.

Mo wa roo wipe, “Wayi, ori mi ti bẹrẹ si i daru diẹ diẹ bayi. Mo n gbọ ohùn kan ti o n sọrọ si mi” Mo saa n tẹsiwaju mo n rin lọ. Ati “Wuu, wuu, wuu.” O n sufe, njẹ o mọ. Mo wa ro wipe, “Wayi, emi ko sọnu. ”Ọmọkunrin, iwọ mọ ibi ti o wa! Kinni o n ṣe ọ gan an? Iwọ ko le e sọnu. Iwọ jẹ ọdẹ ti o dara pupọ, iwọ ko lẹ sọnu.“ Yiyangan fun ara ẹni, o mọ, mọ n fọnnu fun ara mi. Iwọ ko lee fọnnu nipa rẹ. Ni isalẹ lọhun kẹkẹ́ kekere kan n yi, ti o n sọpe, ”Ọmọkunrin, ani o ti sọnu, iwọ naa si mọ bẹẹ. Ẹ rii, o ti sọnu.“

83 Mo saa tẹsiwaju mo n rin lọ. “Ooo, emi ko sọnu, gbogbo rẹ yoo dara pẹlu mi. Emi yoo jana.” Awọn nnkan wa bẹrẹ sii gba ọwọ odi, atẹgun bẹrẹ sii sun mọ mi. Yinyin bẹrẹ sii sọkalẹ, yinyin hominy kekere naa, a maa n pe e ni, yinyin ti o n rọ silẹ“ Mo wa ronu nipa iyawo mi ati ọmọ mi kekere. Emi ko .... mo ro o. Ooo, kaasa!”

Taara mo ti gbọ ọ lẹẹkan sii o wipe, “Emi ni iranlọwọ lọwọlọwọ ni akoko wahala.” Mo jẹ oniwaasu ihinrere nigba naa, ti mo n waasu nihin ninu Agọ ijọsin yii.

Nitori naa, mo wa ro wipe, “O dara, kinni mo le ṣe? Mo da ẹsẹ duro, mo wo ibi gbogbo, ikuuku ti o nipọn ti sọkalẹ bayi. Bi o ṣe ri niyẹn. Ko si ohun ti ẹnikẹni lee ṣe mọ. Mo ro wipe,”Ooo, kini mo le ṣe?“ Mo wa mo wipe, ”Alagba, emi ko yẹ lati wa laaye, mo ti ni igboya ti ara ẹni pupọ ju. Mo ro wipe ọdẹ ni mi, ṣugbọn ko ri bẹẹ.“

84 Ati, arakunrin, mo ti maa n gbẹkẹlẹ E. Ni tita-ibọn, mo ti ni aṣeyọri nla nibẹ. Gẹgẹ bi apẹja, emi ko mọ ẹja n pa, ṣugbọn mo maa n gbẹkẹle E. Tita ibọn, emi ko mọ ibọn i ta, ṣugbọn Oun ti jẹ ki n ṣe aṣeyọri ti o tayọ lagbaye, ẹ rii. Tita ibọn lu agbọnrin ni yaadi ọgọrun meje tabi mẹjọ. Mo ni ibọn kan loke lọhun ti mo fi pa ẹran igbẹ marun-din-ni-ogoji laijẹpe o tase ni igba ẹyọ kan. Iwọ ka nipa eleyi ni ibi-ki-bi, bi iwọ ba lee ṣe bẹẹ, ẹ rii. Emi kọ, Oun ni. Mo ti gbẹkẹle E.

Nibẹ ni mo wa, mo roo wipe, Kinni mo le ṣe? Kinni mo le ṣe?“ Mo tẹsiwaju... Ohùn naa n suumọ, o n suumọ mi sii,” Emi ni iranlọwọ lọwọlọwọ ni akoko wahala, iranlọwọ lọwọlọwọ kan.

Mo roo, “Njẹ Ọlọrun ni O n sọrọ si mi? Mo ṣi ate mi. Mo ni ate ti mo fi n ṣọ igbo, aṣọ inuju pupa ti mo yi mọ ọn. Mo bọ ọ silẹ. Mo bọ kootu mi kaiẹ, o ti tutu diẹ. Mo gbe kootu kalẹ, mo gbe ibọn mi ti igi kan. Mo wipe, ”Baba Ọrun, wayi, emi ko mọ ohun ti mo n ṣe mọ, mo n gbọ ohùn kan ti o n ba mi sọrọ. Njẹ Iwọ ni?

Mo wipe, “Oluwa, emi yoo gba pẹlu Rẹ wipe emi ki i ṣe ọdẹ. Emi ko mọ ọna lati jade kuro ninu igbo yii. Iwọ ni lati ran mi lọwọ. Emi ko yẹ lati wa laaye, pẹlu ohun ti mo ti ṣe yii, ti mo wa si ihin ti, mo si n ro wipe mo mọ pupọ ju nipa igbo ju ki n le sọnu lọ. Mo nilo Rẹ, Oluwa obinrin rere ni iyawo mi. Ọmọ mi kekere ọmọkunrin mi kekere, iya rẹ ti fi aye silẹ, iyawo mi si n gbiyanju lati jẹ iya fun un, emi si gbe e ni iyawo laipẹ ni. Ati nihin ọmọde kan si ni, nibẹ ninu igbo, awọn mejeeji ni wọn yoo si ku ni aṣalẹ yii. Afẹfẹ naa, yoo mu ki otutu mu pupọ pupọ, wọn ko si ni i mọ bi awọn yoo ṣe la. Wọn yoo ku ni aṣalẹ yii. Jọwọ maṣe jẹ ki wọn ku, Ọlọrun. Mu mi lọ ba wọn, ki n le e ri daju pe wọn ko ku. Mo ti sọnu! Mo ti sọnu, Ọlọrun! Emi ko mọ bi n o ṣe mọ ọna jade. Njẹ Iwọ ko ni jọwọ ranmilọwọ? Ki o si dariji mi fun ọna ti imọ-ti-ara-emi-nikan naa! Emi ko lee ṣe ohunkohun laisi Irẹ. Iwọ ni afinimọna mi. Ran mi lọwọ, Oluwa.”

85 Mo dide soke, mo si wipe,“Amin. ”Mo mu aṣọ inuju pelebe mi, kootu mi, mo gbe e, mo de ate mi pada; mo gbe ibọn mi. Mo wipe, “Wayi, emi yoo gbiyanju lati wa ọna ni ọna ti o dara julọ ti mo lee mọ lati jade, pẹlu oye mi ti o dara julọ, emi yoo maa lọ taara ni ọna kan, nitori wipe mo ti rii pe mo n yipo ni aarin kan nibikan ni, emi ko si mọ ibi ti mo wa. Ṣugbọn emi yoo lọ ni ọna ti iwọ ba sọ fun mi, Oluwa Ọlọrun, afinimọna mi.”

Mo bẹrẹ si i rin lọ ni ọna yii. Mo wipe, “Ohun niyi, mo si ni lati mu ara mi gba gbọ. Emi n lọ ni ọna yi. Emi n lọ taara ni ọna yii. Emi ko ya si ọtun tabi osi. Emi n lọ ni ọna yii. Mo mọ wipe mo tọ. Emi yoo tọ ọna yii lọ. Kání mo gba ọna naa lọ ni, emi ti fi ori le Orilẹ-ede Canada, o rii.

86 Ni akoko yii gẹlẹ, mo ni imọlara wipe ọwọ kan kan mi ni ejika, ọwọ kan, o dabi ọwọ ọkunrin kan, o ṣẹlẹ kia to bẹẹ ti mo yipada lati wo. Ko si si ẹnikẹni ti o duro nibẹ. Mo si roo pe, “Kinni iyẹn?” Bibeli ni yi ti o wa ni iwaju mi. Ọlọrun afinimọna ati adajọ mi, wa ni iduro nihin. Mo saa wo oke. Ati taara lẹyin ni ọna yii, imọlẹ mọ si inu ikuuku alagbara naa titi ti mo fi le e ri ile-iṣọ ti o wa ni ori Oke-nla hurricane. Ni lilọ taara mo ti kọ ẹyin sii, pẹlu gbogbo ọgbọn ọdẹ mi ti o dara julọ, mo ti n lọ, mo si kọ ẹyin sii, ilẹ si ti bẹrẹ sii ṣu gan an ni irọlẹ ọjọ naa. Ni kiakia mo yi ẹyin pada, mo wa n fi ori le ibi ti ile-iṣọ naa wa. Mo gba ate mi mu, mo si gbe ọwọ mi soke, mo wipe, “Afinimọna mi mu mi lọ sibẹ, Ọlọrun. Iwọ ni afinimọna mi.”

Mo si bẹrẹ, mo ni lati lọ taara soke rere naa ati ohun gbogbo lati lee de ibẹ, lẹyin lẹyin ọpọ igba. Nigba naa ni okuuku wa bo ilẹ. Awọn agbọnrin n bẹ ni iwaju mi, ati ohun gbogbo bẹẹ. Emi ko tilẹ le e ronu nipa ohunkohun bikoṣe nipa ara mi mọ ni ọna kan, ti mo n goke taara lọ si ori oke yii.

87 Mo si mọ wipe, bi mo ba lee de ibi ile-iṣọ naa, Ọgbẹni Denton ati emi ni a ṣe iranlọwọ lati ta okun naa sibẹ ni akoko iruwe naa. A fa okun tẹlifoonu naa lati ori Oke-nla Hurricane lọ si bii ibusọ mẹta ati aabọ si mẹrin lọ taara si ibudo. Okun naa si lọ taara ni oju ọna tooro naa, ṣugbọn, pẹlu gbogbo yinyin nibẹ, o ṣoro lati le e ri ọna tooro naa, ẹ rii. Afẹfẹ naa si n fẹ ati ohun gbogbo bẹẹ, gbogbo ibẹ ṣokunkun o si kun fun afẹfẹ lile pẹlu yinyin, ni lilọ ni ọna yii, o le lati mọ ibi ti eniyan wa.“ O dara, ohun kanṣoṣo ti mo mọ lati ṣe nigba ti okunkun naa ti bolẹ, emi ko si mọ....mo mọ wipe mo n lọ ni ọna kan, mo si n gun oke naa lọ taara. Nitori pe mo mọ wipe o yẹ ki n gun oke naa, ile-iṣọ naa si wa ni ori oke naa, mo si ni lati rin irin bi ibusọ mẹfa lati de ibi ile-iṣọ naa. Mo saa ro o wipe, ikuuku alagbara naa ti imọlẹ mọ si inu rẹ ni ibusọ mẹfa niwaju, iho kekere kan ni o jẹ, ti mo si fi ni lati rii!

88 Nigba naa, mo fi ọwọ kan gbe ibọn mi, mo si gbe ọwọ keji soke, nitori mo ti sọ okun tẹlifoonu naa mọ awọn igi bẹẹ lọ si isalẹ, ani awọn waya tẹlifoonu naa lọ si ibi ahere naa, ki ọkunrin naa lee ba iyawo rẹ sọrọ ki o si lee pe jade lati ori oke naa. Mo si fẹ ran an lọwọ lati fa waya naa wa si ile ni akoko ikore naa. Mo ṣi abẹ ọwọ mi soke bi eyi, ti mo n wipe, “Ooo, Ọlọrun jẹ ki n le fi ọwọ kan waya naa.” Ọwọ mi n le roro, o si rẹẹ, o si lee pupọ fun mi lati na ọwọ naa ro, mo si nilati mu ọwọ naa walẹ, emi yoo wa yi ọwọ ti mo n gbe soke naa pada lati di ibọn mu, emi yoo wa gbe igbesẹ diẹ pada si ẹyin lati rii daju pe emi ko tase ila naa, emi yoo tun wa gbe ọwọ naa soke, n o si bẹrẹ sii rin, rin lọ. Ilẹ ti n ṣu pupọ, okunkun ṣu, afẹfẹ si n fẹ. Ooo, emi yoo gba ẹka igi kan mu, emi yoo wa sọ wipe, “Ohun niyi! o ti o, ohun kọ niyi.” Ooo, maṣe jẹ ki o mu ohun ti ko daju jade.

89 Lẹyin igba diẹ, nigba ti o ti fẹrẹ de ibi ti emi ti fẹrẹ ṣetan lati sọ wipe emi ko ṣe mọ, ọwọ mi gba ohun kan mu. Ooo, kaasa! Mo ti ri ọna pada lẹyin ti mo ti ṣina. Mo gba waya naa mu. Ni kia, mo gbe ibọn mi silẹ, mo ṣi ate mi kuro ni ori mi, mo si duro nibẹ. Mo wipe, “Ooo Ọlọrun, imọlara aladun ni o jẹ fun ẹni ti o sọnu lati mọ ọna pada sile.” Mo wipe, “Taara ni emi yoo maa lọ titi n o fi de opin waya yii, emi ko ni ju waya naa silẹ. Emi yoo di waya yi mu, ohun ni yoo dari mi taara de ibi ti ohun gbogbo ti o sọwọn ni aye fun mi wa, taara nibẹ, iyawo mi ati ọmọ mi, ni tootọ, wọn ko mọ ibi ti mo wa, wọn ko mọ ina da ninu igbo, wọn ko mọ ohun ti wọn

lee ṣe, afẹfẹ si n fẹ awọn ẹka igi n pariwo nla wọn si n ya danu lara igi. "Emi ko to bẹẹ lati fi waya naa silẹ. Mo di waya yii mu titi ti o fi dari mi taara de ibi ti ohun gbogbo ti o sọwọn fun mi ni aye wa.

90 Iriri ti o buru jai ni eyi jẹ, ati o jẹ iriri nla lati mọ ọna pada, ṣugbọn iyẹn ko to ilaji rẹ. Ni ọjọ kan, mo sọnu sinu ẹṣẹ. Mo lọ lati ijọ de ijọ ti mo n gbiyanju lati wa ohun kan ri. Mo lọ si ijọ awọn ṣeventh-day Adventists, wọn sọ fun mi pe, "Iwọ ma ya ọjọ satide si mimọ, maṣe jẹ ẹran mọ." Mo lọ si ijọ Onitẹbọmi, ijọ Onitẹbọmi Akọkọ, ọkunrin naa wipe, "Iwọ saa dide ki o sọ fun wọn pe iwọ gbagbọ ninu Jesu Kristi Ọmọ Ọlọrun,"emi yoo si ṣe iribọmi fun ọ, o tan. Ofutu fẹẹtẹ ni iyẹn jẹ.

Ṣugbọn ni ọjọ kan, ninu ahere kan, mo gbe ọwọ mi soke, mo gba nnkan kan mu; tabi, jẹ ki n sọ pe, ohun kan gba mi mu, okun iye ni o jẹ, afinimọna naa. Oun si ti dari mi layọ ati alaafia de ipo ti mo de yii. Emi ko ni ja ọwọ mi kuro lara waya naa. Emi n di I ni ọwọ mu ni. Jẹ ki ẹkọkẹkọ ati awọn ijọ ẹlẹkọ adamọ ṣe ohunkohun ti wọn ba n fẹ, emi n di ọwọ afinimọna mi mu ni. Nitori ohun gbogbo ti o wa ni aye ati ni ọrun nigba-ku-gba, ti o ṣe iyebiye fun mi, wa ni opin waya yii. O ti mu mi layọ ati alaafia de ibi ti mo de yii, emi yoo gbẹkẹle E ni iyooku ọna naa. "Nigba ti Oun Ẹmi Mimọ naa ba de, Oun yoo ṣe amọna yin, Oun yoo si dari yin si inu gbogbo imọlẹ."

91 Ẹyin ọrẹ, o ti mu mi de ibi ti mo de ni oni. O ti jẹ ki n jẹ ohun ti mo jẹ bayi. Tayọtayọ emi lee fi Oun han ọ. Oun ni afinimọna kanṣoṣo ti mo mọ ohunkohun nipa rẹ, boya nihin ni aye tabi ni oke lọhun. Oun ni afinimọna mi nigba ti mo ba lọ si igbó ọdẹ. Oun ni afinimọna mi nigba ti mo ba lọ pa ẹja. Oun ni afinimọna mi nigba ti mo ba n ba ẹnikan sọrọ. Oun ni afinimọna mi nigba ti mo ba n waasu. Oun ni afinimọna mi nigba ti mo ba n sun.

Ati nigba ti mo ba ku, Oun yoo maa duro nibẹ ni ibi odo naa, Oun yoo dari mi rekọja ọna naa. Emi ki yoo bẹru ibi kan, nitori Iwọ wa pẹlu mi. Ọpa Rẹ ati ọgọ Rẹ, yoo to mi sọna yoo si ṣe amọna mi re odo naa kọja. Ẹ jẹ ki a gbadura.

92 Baba ọrun, mo dupẹ pupọ fun amọna naa. Ẹni naa ti o n dari mi. Ooo, nigba miiran, Baba, emi ko gbọ ohun Rẹ ni ayika mi, ẹru si maa n ba mi. Mo fẹ ki O wa nitosi mi nitori emi ko mọ akoko ti emi yoo sare lọ lori odo naa. Emi fẹ ki Oun wa nitosi mi Oluwa, maṣe fi mi silẹ. Emi ko mọ ọrọ i sọ, emi ko mọ iwaasu wa. Emi ko mọ ọdẹ i ṣe ninu agingu. Emi ko mọ ẹja i pa ni bebe odo. Emi ko mọ ọkọ̀ mi i wa, ko si ohun ti mo lee ṣe laisi Iwọ. Iwọ ni afinimọna mi. Bi inu mi ti dun to lati sọ fun apejọpọ yii ni aṣalẹ yii, bi Iwọ ti ṣe dari mi ninu gbogbo nnkan wọnyii, ati bi Iwọ ti ṣe mu mi de ibi ti mo de yii!

Mo n ro o ni ijelo; ko ju awọn ọdun diẹ sẹyin lọ, mo dide duro ni opopo-na ati nitori pe ẹbi mi ti ṣe ohun ti o kuna, ko si ẹnikẹni ti o ṣetan lati ba mi sọrọ. Mo pongbẹ fun idapọ. Ko si ẹni ti o fẹ ni ohunkohun i ṣe pẹlu mi. Wọn wipe, "Baba rẹ jẹ ẹni ti o n pọn oti ni ọna ti o lodi si ofin ni." Oluwa ko si ẹnikẹni ti o fẹ ba mi sọrọ, sibẹ mo fẹran awọn eniyan. Ṣugbọn ni ọjọ kan mo gba okun naa mu! Oluwa, wayi mo ro wipe mo ni lati yọkẹlẹ sa lọ si inu aginju ni lati lee ni isimi diẹ. Kini ohun ti o fa eyi? Ki i ṣe nitori ẹni ti mo jẹ, tabi iwe ti mo ka, emi ko ka iwe Kankan, Iwọ ni o jẹ, Oluwa. Ani Iwọ, Oluwa. Iwọ ti jẹ ki n ta ibọn lu ohun ti mo fi ibọn sun, Iwọ ti jẹ ki n ri ẹja pa, ẹja nla naa, nitori wipe Iwọ mọ pe mo fẹ ṣe bẹẹ. Iwọ ti fun mi ni awọn baba awọn iya. Iwọ ti fun mi ni awọn arakunrin ati arabinrin. Iwọ ti fun mi ni ilera mi. Iwọ fi fun mi ni iyawo kan, Iwọ ti fun mi ni ẹbi kan. Iwọ ni afinimọna mi, Oluwa. Jọwọ jẹ ki n di ọwọ Rẹ mu, maṣe jẹ ki n tu u silẹ. Bi o ba rẹ ọwọ kan, emi yoo yii pada si ọwọ keji. Ran mi lọwọ, Oluwa.

93 Njẹ, jẹki ẹnikọọkan nihin di okun-iye kan naa mu. Oluwa, Ẹmi Mimọ naa ti o jẹ iye wa, orisun ti O n fun ni ni iye. Jẹ ki o ṣe amọna gbogbo wa si ilẹ alayọ ni odi keji, nibi ti awọn laala aye ti dopin, ti awọn iṣẹ wa laye ti pari, nigba naa ko ni si ọjọ ogbo mọ, ko ni si awọn alailera mọ, ko ni si awọn oru ti aarẹ n mu ni mọ, ko ni si sisọkun ati gbigba adura mọ. Ko ni si pipeni wa si ibi pẹpẹ, ṣugbọn awa yoo jẹ ọdọ titi laelae, aisan ati ibanujẹ ko ni i si mọ. Ko ni si ẹṣẹ mọ, awa yoo gbe ninu ododo ti Ọlọrun ninu gbogbo igba ti o n bọ wa, ninu ainipẹkun ti ki yoo ni opin. Ẹ gba bẹẹ fun wa, Baba.

Ati bayi, Baba, bi ẹnikẹni ba wa nihin ni aṣalẹ yii ti ko i tii gba okun-iye naa mu, njẹ ki wọn rii ni kia bayi. Jẹ ki Ẹmi Mimọ ẹni ti o ti ṣe amọna ….Mo si lee sọ ọ lati ọkan mi wa pẹlu ọwọ mi ni ori Ọrọ Rẹ, gbogbo igba ni O maa n tọ́. Emi kuna ni ọpọlọpọ igba. Ṣugbọn Oun tọ. Jọwọ jẹ ki O wa pẹlu mi Ọlọrun. Jẹ ki n duro ti I. Njẹ jẹ ki awọn iyooku ti wọn wa nihin, ti wọn ko mọ Ọn ni aṣalẹ yii, jẹ ki wọn gba ọwọ Rẹ ti kii yipada mu, ki a le e dari wọn wa si ọ̀dọ̀ Rẹ.

94 Ni ọjọ kan awa n bọ ni ibi odo naa. Ikuuku yoo bo oju ọjọ ni owurọ naa, pẹlu okun atijọ naa yoo ma pariwo, iyẹn Jọdani ogbologbo naa, awọn igbi omi naa yoo bi pẹlu agbara, iku ti yoo maa fun iye pa ninu wa. Ṣugbọn Ọlọrun, ẹru ki yoo ba mi. Emi ti yanju rẹ ni ọpọ igba sẹyin, mo saa fẹ si aṣibori naa, gẹgẹ bii jagun-jagun, ki n yipo ki n wa wo ẹyin ni ipa oju ọna naa lati ri ibi ti okun na ti dari mi de. Ki n ri gbogbo aginju naa ti mo ti la kọja, ati gbogbo ipa ẹlẹgun naa, ati gbogbo okiti okuta ti o ti pa mi lara, ṣugbọn ti mo n di waya naa mu. Gẹgẹ bi iwọ ti sọ, tabi bi akewi naa ti sọ, "Awọn miiran n la awọn omi kọja, awọn miiran n la ẹkun omi ja,

awọn miiran nlọ ninu idanwo alagbara kọja, ṣugbọn gbogbo wọn ni wọn n la ẹjẹ naa kọja.” Emi si fẹ mu eleyi, ida atijọ naa nihin ti o ti daabo bo mi ni oju ọna naa, ki n si tii pada sii inu apo rẹ, ki n wa pariwo pe, “Baba ran ọkọ-oju omi kekere naa ni owurọ yii, emi n bọ wa si ile.” Oluwa, Iwọ yoo wa nibẹ. Iwọ ṣe ileri rẹ, Iwọ ko si lee kuna.

Bukun olukuluku ti o wa nihin bayi. Bi wọn ko ba ni mọ bi wọn yoo ṣe di okun yii mu, ti wọn ko si ti i fi ọwọ kan an ri, njẹ ki awọn ọwọ mimọ naa ki wọn gbera soke bayi, awọn ọwọ ti n fẹ, awọn ọwọ ti wọn ni ifẹ ọkan naa ki wọn si fi ọwọ ba okun-iye naa ti yoo dari wọn si ifẹ ọkan wọn, ani alaafia pipe ati itẹlọrun, isimi ninu Kristi.

95 Pẹlu ori wa ni itẹba, njẹ ọwọ kan yoo wa ti a o gbe soke ti a o si sọ wipe, “Ẹ jọwọ. Di ọwọ mi mu”? Ooo, ki Ọlọrun bukun n yin.

Nigba ti ọna mi ba n ṣookun,

Oluwa ọwọn, wa ni tosi,

Emi yoo duro nibi odo naa

Dari isiṣẹ mi, di ọwọ mi mu

Oluwa ọwọn mu ọwọ mi,

Maa dari mi lọ.

Njẹ awọn kan tun wa ti wọn yoo gbe ọwọ wọn soke, ti wọn yoo wipe, “Emi fẹ ni imọlara ifi-ọwọ ba ti okun-iye naa ni aṣalẹ yii. Mo fẹ ni imọlara pe Kristi ti dari awọn ẹṣẹ mi ji mi, mo si fẹ di ẹda titun lati wakaki yii lọ.” Ki Ọlọrun ki o bukun yin. Njẹ ẹlomiiran tun wa ti yoo sọ pe,“ Jẹ ki n fi ọwọ ba Ọ, Oluwa. Jẹ ki n padanu ara mi”? Ki Ọlọrun ki o bukun ọ, arabinrin. “Jẹ ki n padanu ara mi, Oluwa, ki n si wa a ri, Oluwa, ninu Rẹ.” Ki Ọlọrun bukun un yin. Ki Ọlọrun bukun un yin. Bẹẹ ni, “Jẹ ki n gbagbe.” Ki Ọlọrun bukun ọ, arakunrin. “Jẹ ki n....” Ki Ọlọrun bukun ọ, arakunrin. “Saa jẹ ki n padanu gbogbo imọ mi.” Ki Ọlọrun bukun ọ, arabinrin. Iwọ ma gbẹkẹle awọn eto atọwọda eniyan kan. Tẹle afinimọna naa, Oun yoo dari rẹ sinu gbogbo otitọ. Dari mi. Jesu Oluwa, dari mi.“ Ki Ọlọrun ki o bukun yin lẹyin lọhun. Ooo, ọpọlọpọ ọwọ ni a gbe soke, wọn n fẹ igbala. Wayi nigba ti a n....

Ibi pẹpẹ wa nihin, a ko lee pe awọn eniyan wa si ibi pẹpẹ, nitori pe awọn eniyan joko si gbogbo ibẹ. Ṣugbọn Oun wa nihin. Ẹyin mọ bẹẹ daadaa, nigba ti ẹ gbe ọwọ yin soke, ohun kan ṣẹlẹ ninu ọkan yin. Jesu sọ wipe, “Ẹnikẹni ti o ba gbọ Ọrọ mi ti o si gba Ẹni ti O ran Mi gbọ, ni iye ayeraye.” Ṣe o ti ọkan rẹ wa? Nigba naa adagun odo ti omi kun kan wa niyin. Ọpọlọpọ akoko ni o wa fun iribọmi. Ẹ jẹ ki a gbadura.

96 Baba wa ọrun, iwaasu kekere ti a mu wa ni ọna ti ko kun oṣuwọn ni aṣalẹ yii nipasẹ ohun hiha kan, Ẹmi Mimọ naa ti ni lati lọ sita nibikan. O lọ si ibi ti a ti pinnu rẹ, ati ọpọlọpọ si wa ni aṣalẹ yii Oluwa, awọn miiran marun-din-logun, awọn miiran ogun ni wọn gbe ọwọ wọn soke pe awọn nilo afinimọna naa. Wọn ni oye pe awọn n gbiyanju lati tan ara wọn jẹ ni. Wọn n gbiyanju lati sọ wipe, “Emi ko ni wahala kan”, ṣugbọn ni isalẹ ọkan wọn, wọn mọ wipe, ko ri bẹẹ. Wọn fẹ ni imọlara Rẹ Oluwa. Wọn n fẹ afinimọna naa. Wọn fẹ bu ọwọ lu iwe lati darapọ mọ ọn Yin. Ile itaja Yin ki i kun akunju. Wọn fẹ bu ọwọ lu iwe fun irinajo yin. Wọn ko mọ bi wọn yoo ṣe de ibẹ. Ko si ẹni ti o mọ ọna ati mu wọn de ibẹ. Iwọ ni Ẹni kanṣoṣo na. Wọn n bọ fun afinimọna ti Ọlọrun pese silẹ, Ẹmi Mimọ. Wọn ti gbe ọwọ wọn soke.

97 Ooo, Iwọ Ẹmi Mimọ ati afinimọna, sọkalẹ wa si ori wọn. Dari gbogbo ẹṣẹ ji. Dari gbogbo aiṣedeede wọn ji. Mu wọn wa si inu ara Kristi ni aṣalẹ yii, nibi ti wọn yoo ti ni ibu omi Ọlọrun ti yoo maa ṣan nipasẹ okun iye naa ti yoo dari wọn sọkalẹ lọ si odo Jọdani, ati rekọja odo Jọdani lọ si ilẹ-ileri. Njẹ ki wọn lọ taara lẹyin Ọrọ Ọlọrun naa. Ọrọ Ọlọrun sọ wipe, “Ẹ ronu-piwada, ki a si baptisi yin ni orukọ Jesu Kristi.” Njẹ ki wọn ma gbiyanju lati lọ nipa rẹ ni ọna miiran. Njẹ ki wọn tẹle Ọrọ Ọlọrun naa taara, nitori Oun ni Ẹni naa ti yoo fi ni mọna. Eyi ni igbesẹ lati gun oke titi ti a o fi di afinimọna naa mu. Gba bẹẹ fun wa, Oluwa. Njẹ ki wọn di tirẹ. Wọn wa ni ọwọ Rẹ bayi gẹgẹ bi i ere-ikogun, ko si ẹni kan ti o lee ja wọn gba kuro ni ọwọ Rẹ. Mo gbagbọ wipe Iwọ yoo gba wọn gẹgẹ bii awọn ẹni igbala. Mo gbagbọ pe wọn gbe ọwọ wọn soke, wọn ki ba ti ṣe bẹe lati gbe ọwọ wọn laijẹ pe ohun kan ba wọn sọrọ. Iwọ ni o, Ẹmi Mimọ ati afinimọna.

Wọ ri i wipe wakati naa ti sunmọle, ikuuku ti n bolẹ aye, awọn ẹkọkẹkọ nla ati awọn nnkan wa ni isọkan papọ, awọn ijọ n korajọ pọ, wọn n wa papọ. Ati, Ooo, Ọlọrun, bi wọn ṣe n gbiyanju lati sọ pe, “Gbogbo awọn ti wọn ni awọn nnkan ti wọn yatọ ni lati lọ si Alaska.” Ati gbogbo idẹrubani ti wọn n ṣe, awọn nnkan wọnyii ko jẹ tuntun si wa, afinimọna nla naa ti fi iyẹn han wa ni ipa ti Ọrọ Ọlọrun. Awa ṣẹṣẹ nla ipa iyẹn kọja ni.

Baba, Ọlọrun, Iwọ ba wọn sọrọ ni aṣalẹ yii, emi si fi wọn fun Ọ bayi gẹgẹ bi ami iṣẹgun ti Ọrọ Ọlọrun

naa. Ni orukọ Jesu.

98 Wayi awọn aṣọ inuju wa ni ori tabili nihin Baba, wọn wa fun awọn alaisan, ọmọ kekere kan, boya, awọn iya kan, awọn arabinrin kan, awọn arakunrin kan, awọn piini-irun ti a ki bọ inu wọn. Ati bayi mo mu wọn sun mọ ara mi. Wayi, a kọ wa ninu Bibeli pe wọn mu awọn aṣọ inuju ati awọn ibantẹ kuro ni ara Paulu, a si mu awọn alaisan lara da, awọn ẹmi aimọ si jade kuro lara awọn eniyan. Wayi, awa mọ, Oluwa pe, eniyan ni Paulu, eniyan lasan ni o jẹ. Ṣugbọn itami-ororo ti Ẹmi Mimọ ti o wa lori rẹ ni o bukun awọn aṣọ inuju naa, ati igbagbọ ti awọn eniyan ni wipe o jẹ apositeli Rẹ. Wayi a ti mu Paulu kuro lọdọ wa, ṣugbọn afinimọna naa ṣi wa pẹlu wa, Oun si wa nihin. Ọlọrun, mo gbadura pe ki Iwọ ki o bukun awọn aṣọ inuju wonyii, jẹ ki afinimọna naa dari wọn si ipa naa, ani ijọwọ ara-ẹni patapata naa.

99 A tun sọ fun wa pe nigba ti Israẹli n tẹle afinimọna wọn, ti wọn si de ibi odo Jọdani, taara lọ (mo, fẹ sọ pe) ibi Okun pupa. Ni ibi ojuṣe wọn gan an fun Ọlọrun, a da wọn duro, afinimọna naa si dari wọn lọ sibẹ. Eeṣe? O jẹ lati fi ogo Rẹ han. Ati nigba ti gbogbo ireti de opin, Ọlọrun wa wo isalẹ nipasẹ ọwọn ina, ẹru si ba Okun iku naa o si ṣan pada, ọna kan si ṣi silẹ fun Israẹli lati rin kọja lọ si ilẹ-ileri.

Ni tootọ, Oluwa, Ọlọrun kan naa ni O jẹ. Boya Kristẹni gan an ni awọn eniyan wọnyii jẹ, boya wọn wa ni ipa ọna wọn fun Ọlọrun, ṣugbọn a ti mu wọn wa si ibi ti ọta ti ka wọn mọ yii, ti aisan ti ka wọn mọ yii. Wo isalẹ nipasẹ ẹjẹ Jesu ni aṣalẹ yii, ki aya ki o ja eṣu, yoo si sun si ẹyin, awọn ọmọ Rẹ yoo si rekọja lọ si ilẹ-ileri ti ilera pipe. Gba bẹẹ fun wa, Baba. Mo ran wọn lati ara mi, ni orukọ jesu Kristi.

100 Mo gbe ikorajọpọ mimọ yii wa si iwaju Rẹ, nipa igbagbọ mo mu wọn taara wa si ibi pẹpẹ ologo ti Ọlọrun ni odikeji ọrun, fun gbogbo ifẹ-ọkan aisan, ohun yoowu ti wọn ni ti o kuna, ohunkohun, Ọlọrun ti o kuna ni igbesi aye wọn nibikibi, fọ wọn mọ, ṣe wọn ni tirẹ, wo wọn san, Baba. Njẹ ki agbara ti o gbe Jesu dide kuro ninu iboji, sọ ara kiku wọn di aaye ki o si sọ wọn di ẹda-titun ninu Kristi. Fun wọn ni ilera pipe ki O si fun wọn ni okun lati sin Ọ.

Ranti mi, Oluwa, Iranṣẹ Rẹ ni mo jẹ. Ranmilọwọ, ti mo n duro, ti mo nilo adura. Mo si gbadura pe ki Ẹmi Mimọ ki o ṣe amọna wa, ki o si lo wa, ki o si dari wa titi di ọjọ ti awa yoo ri Jesu Kristi ni ojukoroju ni akoko bibọ ologo Rẹ nigba ti awa yoo pade Rẹ ni oju ọrun ni akoko igba lọ soke. Ni orukọ Jesu ni awa beere rẹ. Amin.

101 Mo fẹran Rẹ emi… (Njẹ iwọ fẹ Ẹ?)

Nitori pe O kọkọ fẹ mi;

O si ra igbala mi

Ni ori igi ti Kalfari.

Wayi, bi ẹyin ko ba ni ifẹ ara yin, ẹyin ti ẹ ri ara yin, bawo ni ẹ o ṣe fẹran Rẹ Ẹni ti ẹyin ko ri? Wayi, nigba ti a ba n kọ orin yi, "Mo fẹran Rẹ, "ẹ jẹ ki a fun ẹni ti o wa ni ẹgbẹ wa ni ibọwọ ifẹ ti o dara.

Mo fẹran Rẹ… (Arakunrin Branham bọ ọwọ pẹlu awọn ti wọn wa ni ayika rẹ)

(Ki Ọlọrun ki O bukun ọ, Arakunrin Neville)

Ni ori igi ni Kalfari.

Wayi, ẹ jẹ ki a gbe ọwọ wa soke si I.

Mo fẹran Rẹ, mo fẹran Rẹ.

Nitori ti O kọkọ fẹ mi;

O si ra igbala mi.

Ni ori igi ni Kalfari.

102 Fun orin ti o dara kan, njẹ iwọ yoo fẹ gbọ ọkan? Mo loye wipe awa ni adari orin kan ti o jẹ ajinhinrere nihin, ẹni ti o wa lati Indianapolis. Mo gbagbọ pe o maa n kọrin ni Cadle Tabernacle, ṣe bẹẹ ni? O ti dara. Ipo rẹ niyẹn ni Cadle Tabernacle. Awọn melo ni wọn ranti E. Howard Cadle? Ooo, akiika! Ki Ọlọrun jẹ ki ọkan rẹ iyebiye naa ki o sun un re. Ẹyẹ olohun-gooro ti oju ọrun naa, obinrin kan ti mo fẹran lati maa gbọ ki o kọ orin, ni Iyaafin Cadle, ti o nkọ "Ki o to fi yara rẹ silẹ ni owurọ yii, njẹ o ranti lati gbadura ni orukọ Kristi Olugbala wa, gẹgẹ bi asà loni?"

103 Ni odikeji opopo-na taara ni owurọ ọjọ kan, ninu ahere iyara meji kekere ti atijọ naa, mo dide soke, mo fẹ

lọ lati lọ da ina. Sitoofu naa ko ran. Mo si gbiyanju lati ṣa ina sii, afẹfẹ si wa o si fẹ ina na pa si oju mi. Otutu si mu, mo ti fẹrẹ gan pẹlu otutu. Yinyin si wa ni gbogbo ori ilẹ, emi ko wọ bata, mo si n gbiyanju lati mu ki sitoofu oni Pangolo yii ran, aro kekere kan si wa ti a fi n yan nnkan si wa ninu rẹ. Mo si gbiyanju… Meda ati emi ṣẹṣẹ ṣe igbeyawo ni. Mo si n gbiyanju, awọn igi idana naa tutu, wọn ko si ranna, mo si joko nibẹ, ro o wo pe, "Ooo, akiika! emi yoo gbiyanju lẹẹkan sii. Mo ni lati lọ si ibi iṣẹ, mo si n fẹ ina sitoofu ti o ti gbo naa bẹẹ. Mo si na ọwọ, mo si ṣi redio naa, obinrin naa si bẹrẹ sii kọ orin pe, "Ki o to fi yara rẹ silẹ ni owurọ yii, njẹ o ranti lati gba adura. Mo saa ṣubu gbalaja silẹ ni, ni orukọ Kristi Olugbala wa gẹgẹ bi àsà kan loni?" Ooo, bi mo ṣe fẹran lati maa gbọ orin obinrin naa to!

104 Nigba ti mo ba rekọja si odikeji odo lọjọ kan, mo gbagbọ pe emi yoo gbọ ohun iyaafin Cadle ti yoo joko si odikeji lọhun. Njẹ o mọ, mo ti maa n ni adehun ni gbogbo igba. Ni odikeji odo naa yii, nibẹ ni igi ti ewe rẹ ki i rẹ nigba gbogbo naa wa, o mọ, igi iye naa, ati ni odikeji odo naa ni ẹgbẹ akọrin awọn angẹli naa yoo ti maa kọrin lọsan ati loru, nitori pe ko ni si oru nibẹ, wọn yoo maa kọrin ni gbogbo ọjọ, ẹ rii. Emi yoo wa ibi kan fun ara mi, emi yoo si joko n o si tẹtisi orin naa. Mo gbagbọ pe emi yoo gbọ orin iya-aafin Cadle ni odikeji nibẹ ti yoo maa kọrin.

Ki Ọlọrun ki o bukun arakunrin wa. Mo gbagbe orukọ rẹ. Arakunrin, kinni orukọ rẹ? Arakunrin Ned Woolman ni yoo kọ orin fun yin bayi. Arakunrin woolman, inu wa dun lati ni yin pẹlu wa ni aṣalẹ yii.

MESSAGE hub online

www.messagehub.info

Ìwàásù lati ẹnu

William Marrion Branham

"... Ati ni ọjọ́ ohùn angẹli keje ..." Ifihan 10:7